Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 154-171 | jan./ jun.2025.

# Àfihàn agbára èṣù nínú àsàyàn ewì ajẹméṣu

# The Reflection of Èṣu's Power in the Selected Èṣù-Related Poetry

**Taofiq SA'ADU, Ph.D** *

ORCID iD https://orcid.org/0009-0000-1708-2805

**ÀṢAMỌ̀**

Isé yìí ṣe àfihàn agbára Èṣù nínú ewì ajẹméṣù. Iṣẹ́ yìí tún ṣe ìtúpalẹ̀ bí agbára Èṣù ti ṣe jẹyọ nínú àṣàyàn ewì-ajẹméṣù pàápàá jùlọ ẹṣẹ-Ifá. A ṣe èyí pẹ̀lú èrò láti ṣàlàyé àgbékalẹ̀ àti àkóónú ewì ajẹméṣù gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe wà nínú ẹsẹ Ifá àti àlàyé nípa àbùdá agbára Èṣù. Abala méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ọgbọ́n ìṣèwádìí tí a lò nínú iṣẹ́ yìí. Abala àkọ́kọ́ ni a ti ṣe ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nu-wò fún àwọn Babaláwo, àwọn olùsìn Èṣù àti àwọn apohùn ìbílẹ̀ ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun àti Ọ̀yọ́. Ìdí tí a fi ṣe àṣàyàn ìpínlẹ̀ wọ̀nyí ni pé, ibẹ̀ ni a ti lè rí àwọn ìlú ìṣẹ̀nbáyé tí a ti lè rí ewì ajemẹ́ṣù gbà ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Ní abala kejì ọgbọ́n ìṣèwádìí yìí ni a ti yẹ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìwé tí ó wúlò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí wò bí i; àwọn ìwé Ifá, átíkù inú jọ́nà àti ìtàkùn àgbáyé. Àwọn àkójọ-èdè-fáyẹ̀wò wọ̀nyí ni a ṣe ìtúpalẹ̀ wọn pẹ̀lú tíọ́rì àbùdá oníbejì. Àbájáde iṣẹ́ yìí fi Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà ti ó lágbára àyínìke àti àyínnìpadà, tí ó sì ń pè fún ìdájọ́ òdodo àti àyípadà rere. dípò ojú aṣebi tí àwọn èsìn àjèjì fi wò ó. Iṣẹ́ yìí ṣe àfikún ìmọ̀ tí ó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ lórí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, ìmọ̀ abínibí Yorùbá àti láti ṣe àtunṣe sí èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn ẹ̀sìn àjèjì nípa Èṣù.

**KEYWORDS**

Èṣù, Èsè-Ifá, Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá, tíọ́rì ìfojú ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wo lítíréṣọ̀

**ABSTRACT**

This study examines the reflection of Èṣù's power in the selected Èṣù-related poetry, analyzing how the deity's influence is embedded in the Yoruba oral poetry, most especially Ifá literary corpus. The research adopts both primary and secondary sources of data collection. The primary data were obtained through in-depth interviews with Ifá priests, Èṣù worshipers and traditional orature in Ọ̀ṣun and Ọ̀yọ́ states, Southwestern Nigeria, to collect Èṣù-related poetry that encapsulates the power and role of Èṣù divinity. Secondary data were gathered from relevant Ifá texts, scholarly articles, and online resources. The collected data were transcribed and analyzed within the theoretical framework of binary complementarity, which emphasizes the dual yet interdependent nature of forces in literature, culture, and societal structures. Findings reveal that Èṣù embodies the principle of duality, functioning as both a positive and negative force -an agent of balance, mediation, and transformation within the esu-related poetry, especially Ifá literary tradition. It challenges colonial distortions that depict Èṣù as purely malevolent. The study contributes to the discourse on Yoruba oral literature, indigenous knowledge systems, and the nuanced reinterpretation of African religious traditions in contemporary scholarship.

**KEYWORDS**

Èṣù, Èsè-Ifá, Ifá divination, Yoruba oral literature, Sociology of literature

* Department Of Yorùbá, Adéyemí Federal University Of Education, Ondo, Nigeria, E-mail: taofiqsaadu@gmail.com ou saadut@aceondo.edu.ng

**Ìfáárà**

Àkíyèsí fi hàn pé onírúurú Òrìṣà ni Olódùmarè dá tí ó sì fún wọn ní agbára ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ìwádìí fi hàn pé ọ̀kànlénírinwó (401) ni àwọn Òrìṣà tí ó wà. Lára wọn ni a ti rí àwọn tí ó ń ṣe rere àti àwọn ajogun tí wọ́n ń ṣe ibi. Àwọn Òrìṣà tí ó ń ṣe rere jẹ́ igba (200) nígbà tí àwọn ajogun náà sì jẹ́ ìgbà (200). Ọ̀kan tí ó lé lórí wọn ni Èṣù, tí ó jẹ́ alàgàta láàárín àwọn méjèèjì. Ìdí nìyí tí wọ́n fi gbàgbọ́ pé aṣerere-ṣebi ni Èṣù. Àwọn onímọ̀ bi Barber (1990) tako òǹkà àwọn Òrìṣà yìí, nígbà tí ó sọ pé àwọn Òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá pọ̀ ju iye tí ènìyàn lè sẹ òǹkà wọn lọ. Alana (2004) pín àwọn Òrìṣà Yorùbá sí ọ̀wọ́ mẹ́ta. Àkíyèsí fi hàn pé, lára ìpín àkọ́kọ́ àwọn Òrìṣà tí wọ́n ti wà lọ́dọ̀ Olódùmarè lati ìpìlẹ̀ṣẹ̀ ayé wá, tí Alana (2004) mẹnubà nínú ìpínsísọ̀rí rẹ̀ ni ni Èṣù Ọ̀dàrà, Ọ̀rúnmìlà, Ògún, Ọbàtálá àti Ṣàngó wà. Èyí túbọ̀ fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àgbà Òrìṣà ni Èṣù. Èrò yìí náà ṣe déédéé pẹ̀lú àwíjàre Ògúnbọ̀wálé (1980:7) tó sọ pé:

Bí a bá tò ó ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lẹ́, Èṣù ni igbákejì Èdùmàrè. Èṣù ni ọba àjípè. Òun kan náà ni à ń pè ní Ẹlẹ́gbára. Kí á tó bọ Ifá, kí á tó bọ Ṣàngó, a gbọ́dọ̀ júba Ẹlẹ́gbára. Kí á tó bọ Yemọja, kí á tó bọ ìbejì, a gbọ́dọ̀ ta epo sílẹ̀ fún Èṣù.

Àrífàyọ wa nínú àyọlò òkè yìí fi Èṣù sí ipò igbákejì Olódùmarè. Bí a bá wo èrò yìí dáadáa, a ó rí i pé ó ṣe déedée pẹ̀lú ìtàn-ìwáṣẹ̀ nípa Èṣù. Ìwádìí fi hàn pé Èṣù ni ó súnmọ́ Olódùmarè jù ní ìsálú-ọ̀run. A tún gbọ́ pé Èṣù jẹ́ Òrìṣà tí ó ní òmìnira, tí ó si ní ọgbọ́n àrékérékè láti ṣe ohunkóhun ti ó bá fẹ́. Ìdí nìyí tí àwọn ènìyàn àwùjọ kan fi gbà á ni igbákejì Olódùmarè. Nítorí náà, a lè sọ pé Èṣù jẹ Òrìṣà tí ó gbajúmọ̀ jù láàárín gbogbo Òrìṣà yòókù, ó sì ní àwọn olùsìn káàkiri orílẹ̀ àgbáyé.

Ní àwùjọ Yorùbá, onírúurú àwọn Òrìṣà tí a mẹ́nubà yìí ló wà tí àwọn ènìyàn àwùjọ sì máa ń jọ́sìn tàbí tí wọ́n ń rúbọ sí láti fi wá ojúrere wọn fún ohunkóhun tí wọ́n bá ń wá. Odù Ifá *Ọ̀ṣá Èṣù* (Ọ̀ṣá lọ́tùn-ún, Ogbè lósì) tí a gbọ́ lẹ́nu abẹ́nà ìmọ̀ wa Babaláwo Ifániyọ̀ Àtàndá ií ó sàlàyé báyìí pé:

Ifá ló lòní
Ifá ló lọ̀la
Ifá ló ni ọ̀túnla pẹ̀lú
Èṣù Ọ̀dàrà ló ni ọjọ́ gbogbo,
Ọ̀rúnmìlà ní ọjọ́ mẹrin lòòṣà dá
A díá fún Ọ̀rúnmìlà
Ifá ó lọ gba ọjọ́ wá sílé ayé (Babaláwo Ifániyọ̀ Àtàndá)

Ohun tí a rí fàyọ nínú Ìtàn inú àyọlò ẹsẹ Ifá òkè yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé gbogbo ọjọ́ ni ti Èṣù. Ìtàn-ìwáṣẹ̀ sọ fún wa pé nígbà tí Ọ̀rúnmìlà lọ gba ọjọ́ lọ́dọ̀ Olódùmarè, ọjọ́ mérin ni Olódùmarè kó fún un lóde ọ̀run pé kí gbogbo àwọn ọ̀kànlénírinwó (401) Irúnmọlẹ̀ tí ó wà lóde ìṣálayé ó pín. Ọbàtálá ló mú ọjọ́ ọ̀ṣẹ̀, Ọ̀rúnmìlà ló mú ọjọ́ awo, Ògún ló mú ọjọ́ Ògún, nígbà tí Ṣàngó mú ọjọ́ jàkúta. Ìtàn sọ pé gbogbo àwọn irinwó (400) Irúnmọlẹ̀ ni wọ́n tò ní ọgọ́ọ̀rún sí ẹ̀yìn ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn Òrìṣà tí wọ́n mú ọjọ́ yìí. Èṣù nìkan ni kò tò ṣẹ́yìn Òrìṣà kankan. Ó ní àwọn jọ ni gbogbo ọjọ́ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ni, nítorí pé kò sí ọjọ́ tí òun Èṣù kò lè ṣe ènìyàn. Kò sì sí ọjọ́ tí wọn yóò bọ àwọn Òrìṣà yòókù tí wọn kò ní bọ òun náà. Èyí jẹ́ àbùdá kan gbòógì tí ó sọ Òrìṣà yìí di alágbára láàárín gbogbo ọ̀kànlénírinwó Irúnmọlẹ̀.

Òrìṣà tí ó lágbára láàárín àwọn Irúnmọlẹ̀ yòókù ni Èṣù. O sì tún ní ipa pàtàkì lórí àwon olùṣìn rẹ̀. Nítorí náà, ọ̀pọ̀ ewì alohùn Yorùbá ní ó máa ń júwe agbára Èṣù nínú àgbékalẹ̀ wọn, àwọn apohùn sì máa ń kọ́kọ́ júbà Èṣù láti lè fi ìmọ́rírì agbára rẹ̀ hàn kí ó máá baà dà wọ́n lágbo nù. Ọ̀kan lára ewì alohùn Yorùbá tí ọ̀rọ̀ nípa Èṣù ti máa ń hànde jù ni ẹsẹ-Ifá. Yàtọ̀ sí pé kò sí Òrìṣà Yorùbá tí Ifá kò sọ̀rọ̀ nípa wọn. Ṣùgbọ́n, ó dà bíi pé, ọ̀rọ̀ nípa Èṣù pọ̀ díẹ̀ nínú eṣe-Ifá ju ti àwọn Òrìṣa yòókù lọ nítorí pé ìbáṣepọ̀ ìpìlẹ̀ wá láàárín àwọn méjèèjì. Yàtọ̀ sí pé ó jẹ́ ọlọ́pàá Olódùmarè, agbẹ́bọyọ́run, òun yìí nìkan ni ìtàn tún sọ

fún wa pé o mọ́ ojú ìléjà àwọn ajogun, ní ìdí èyí, Èṣù ọ̀dàrà ní agbára láti ti ire sí ènìyàn àti àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù, bákan náà sì ni ó lè yọ̀ǹda kí ibi ó ṣẹlẹ̀ sí ẹni tí kò bá fi tiẹ̀ ṣe. Àkíyèsí yìí ṣe déédéé pẹ̀lú èrò Abímbọ́lá (1968) tó sọ pé àwọn ajogun mẹ́jọ ni wọ́n máa ń da ọmọ aráyé láàmú, Èṣù Ọ̀dàrà sì ni ọ̀gá wọn nítorí pé ọmọ ọ̀dọ̀ Èṣù ni gbogbo àwọn ajogun mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ ń ṣe. Abímbọ̀lá (1968:xxi) sọ pé:

Ifá fi yé wa wí pé mẹ́jọ ni àwọn ajogun. Àwọn mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ náà ni *Ikú, Àrùn, Òfò, Ẹ̀gbà, Ọ̀ràn, Èpè, Ẹ̀wọ̀n, Èṣe*. Gbogbo àwọn ajogun tí a dárúkọ wọ̀nyí, ọmọ ọ̀dọ̀ Èṣù ni wọ́n jẹ́. Àwọn ajogun kò fẹ́ ire fún àwa ènìyàn bí kò ṣe ibi. Wọ́n kò fẹ́ ire fún àwọn Òrìṣà náà nítorí pé àwọn Òrìṣà wà fún ìrànlọ́wọ́ àwa ẹ̀dá. Èṣù ló sì jẹ aláàlà fún àwọn ajogun, àwa ènìyàn àti àwọn ìbọ kì í jẹ́ kí àwọn ajogun ó dìgbò lu ẹni tí ó bá rúbọ.

Àlàyé Abímbọ̀lá (1968) nínú àyọlò òkè yìí jẹ́ kí à mọ̀ pé gbogbo ẹni tí ó bá ti rúbọ fún Èṣù, Èṣù kò ní jẹ́ kí agbára àwọn ajogun ó ká irú ẹni bẹ́ẹ̀. Ẹni tí ó bà sì kọ̀ tí kò rúbọ fún Èṣù, Èṣù yóò máa wo irú ẹni bẹ́ẹ̀ níran kí àwọn ajogun ó fi ṣe ohun tí ó bá wù wọ́n. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé "ẹni tó bá rúbọ fún Èṣù ni Èṣù yóò gbè". Fún ìdí èyí, agbára Èṣù ọ̀dàrà pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ débi pé kò ṣe é fọwọ́ rọ́ ṣẹ́yìn láàárín gbogbo imọlẹ̀. Ìdí pàtàkì yìí ló jẹ́ kí iṣẹ́ yìí ó tanná ìwádìí wo àfihàn agbára Èṣù nínú àwọn àṣàyàn ewì ajẹ́mẹ́ṣù.

**Tíọ́rì Ìṣàmúlò fún Iṣẹ́ yìí**

Ìlò tíọ́rì ṣe pàtàkì nínú àyẹ̀wò iṣẹ́ ìwádìí ewì alohùn Yorùbá, pàápàá jùlọ nínú àfihàn agbára Èṣù nínú ewì ajẹméṣù. Tíọ́rì àbùdá abèjì tí a ṣe àmúlò nínú iṣẹ́ yìí ràn wá lọ́wọ́ láti wo ipa àbùdá onibeji ninu àkójọ-èdè-fáyẹ̀wò tí a gbà sílẹ̀ láti ẹnu àwọn abọrẹ̀, àwọn babaláwo, àti àwọn akéwì tí wọ́n ń lò Èṣù nínú ìpohùn wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ kan gbà pé ìsàmúlò tíọ́rì nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ kì í ṣe òfin kànǹpá, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìlànà kan pàtàkì tó dára láti lò fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ ní ọ̀nà tí yóò gbà ní ìtumọ̀ tó péye. Nínú àwárí ìtumọ̀ àti agbára Èṣù, a rí i pé ó jẹ́ Òrìṣà tí ó ní àbùdá onibèjì. Ìdí nìyí tí a fi lo tíọ́rì àbùdá onibèjì fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí.

**Tíọ́rì Àbùdá Abèjì**

Tíọ́rì tí a lò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí ni tíọ́rì àbùdá onibeji. Tíọ́rì àbùdá onibeji ní ṣe pẹ̀lú méjì méjì tí Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè dá ilé ayé. Èyí tí a lè túmọ̀ sí, òkè àti ilẹ̀, ọ̀tún àti òsì, ire àti ibi, akọ àti abo, gbígbóná àti tútù, líle àti dídẹ̀, ọkùnrin àti obìnrin, dudu ati funfun àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èrò yìí ni Ilésanmí (1988:98) fi hàn báyìí pé:

Yorùbá gbà pé méjì méjì ni nǹkan ń rìn: tibi-tire, tọkọ-taya, tọ̀sán-tòru, tòkè-tilẹ̀, tilé-toko àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Wọ́n tilẹ̀ gbà pé ènìyàn méji ni Olódùmarè kọ́kọ́ ṣẹ̀dá sí ilé ayé yìí; àti pé ìbejì ni àwọn ẹni méjì náà; àwọn ni Ìdámùrì àti Èyílà tó jẹ́ pé ọyún àti ẹ̀jẹ̀ tó wà nínú igbá méjì tí Olódùmarè gbé fún Ọ̀rúnmìlà ni Ifá dà pọ̀ tó sì di ìgbékalẹ̀ tuntun lábẹ́ igi àlọ́yè tàbí igi ńlá. Ọ̀kan ọkùnrin, èkejì obìnrin ni ẹ̀dá méjì náà jẹ́,

Bí a bá wo èrò Ilésanmí (1988:98) nínú àyọlọ̀ òkè yìí dáadáa, a ó rí i pé, tíọ́rì àbùdá onibeji kì í ṣe àjèjì ní àwùjọ Yorùbá. Àkíyèsí fi hàn pé láti ọ̀dọ̀ àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun ni ìmọ̀ yìí ti wọnú ìmọ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Àwọn onímọ̀ bí i; Anton (1981) àti Anita àti Paulus (2019) gbà pé láti inú ìmọ̀ ìsirò ní ìlànà onibeji ti bẹ̀rẹ̀. Àkíyèsí fi hàn pé onímọ̀ ìsirò kan tí ó jẹ́ ọmọ ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ George Boole ló ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀ka ìmọ̀ kan tí ó pè ní *Boolean Logic* nínú ìmọ̀ kọ̀ǹpútà. Láti ìgbà náà ni ìlànà onibeji ajẹmọ́-òǹkà ti di lílò nínú ìmọ̀. Àwọn kan tilẹ̀ gbàgbọ́ pé ọ̀rọ̀ nípa òǹkà ti wà tipẹ́. Òun sì ló bí àgbéǹde ẹ̀rọ aṣòǹkà ṣùgbọ́n ẹ̀rọ yìí kò kájú rẹ̀ láti kógo àwọn iṣẹ́ ajẹmọ́ṣirò já. Èyí ló sì ṣe okùnfà ìdásílẹ̀ irinṣẹ́ aṣòǹkà tí yóò kógo já, tí a lè sọ pé ó bí ìlànà George Boole tí ó pè ní *Boolean Logic*. Ìlànà onibeji aṣòǹkà ní ó ni ṣe pẹ̀lú nǹkan méjì: iró tàbí òtítọ́ èyí tí wọ́n ń fi òǹkà '1' tàbí '0' dípò. Èrò yìí fara pẹ́ ti Ọpẹ́ọlá (2001) nígbà tí ó ṣe àgbéyẹ̀wò ìlànà onibeji nínú ẹsẹ-Ifá. Ọpẹ́ọlá (2001:8) sọ pé:

The Yorùbá arriving at the equatorial forest in Ifẹ̀, had to invent instruments to express the principles of binary system which form the basis of the Ifá literary corpus. The

concepts even, double, two as established in the use of the instrument ìbò (to say yes=2 and no=1).

(Àwọn Yorùbá tí wọ́n dé sí igbó ní Ilé-Ifẹ̀ ní láti ṣe àgbékalẹ̀ irinṣẹ́ tí wọ́n fi ṣàlàyé àbùdá onímeji tí ó jẹ́ ìpìlẹ̀ fún ẹ̀ṣẹ̀-Ifá wọn. Ohun tí ó ní ṣe pẹ̀lú adọ́gba, méjì, ééjì gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe wà ní irinṣẹ́ ìbò. Èyí tí a lè sọ pé bẹ́ẹ̀ ni tí ó dúró fún òǹkàn 'eéjì' tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́ tí ó dúró fún òǹkà 'óókan' wáyé láti inú).

Àyọlò òkè yìí náà jẹ́rìí sí i pé ìlànà àbùdá onímeji kì í ṣe ti ìlú kan tàbí ti ìran kan, káríayé ni, kì í sì í ṣe àjèjì sí ìran Yorùbá nítorí pé gbogbo ohun tí ó rọ̀ mọ́ ètò ìgbé ayé wọn ni ó ní ṣe pẹ̀lú àbùdá onímeji gẹ́gẹ́ bí Ilésanmí (1988) ti ṣe àgbékalè rẹ̀. Ohun tí a tún ṣàkíyèsí ni pé kò sí ẹ̀ká-ẹ̀kọ́ tí ìmọ̀ àbùdá onímeji yìí kì í tí jẹ yọ. A sì rí ẹ̀rí èyí nínú Anita àti Paulus (2019:83) tí wọ́n sọ pé:

Binary opposition does not only serve in language when it comes to conceptual understanding. Many fields of studies use binary opposition as their tool in presenting their ideas. For example, there is famous concept like "yin" and "yang" in Chinese philosophy, "angel" and "demon" in religious like Christianity, to show concept of gender, there is "male" and "female" in biology, etc. This shows that binary opposition is indeed indispensable and fundamental in every field of study including literature.

(Ìlànà onímeji kì í ṣe nípa èdè nìkan nígbà tí a bá fẹ́ ní àgbọ́yé nípa rẹ̀. Ọ̀pọ̀ ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ni wọ́n ń ṣe àmúlò ìlànà onímeji yìí gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ láti fi ṣe àgbékalẹ̀ èrò wọn. Bí àpẹẹrẹ, èrò kan tí o gbajúmọ̀ nínú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Chinese ni *yin* àti *yang* tí a lè túmọ̀ sí ẹ̀mí àìrí aṣerere àti ẹ̀mí àìrí aṣebi nínú ẹ̀sìn bí ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn-Jésù, láti ṣe àfi hàn èrò takọ-tabọ, a ni ọkùnrin àti obìnrin nínú ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ nipa ẹ̀dá *Biology,* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí fi hàn pé ìlànà onímeji ṣe pàtàkì tí kò sì ṣé é yà kúrò nínú ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ kọ̀ọ̀kan tó fi dórí ẹ̀ka ẹ̀kọ́ lítíréṣọ̀).

Ti a bá wo àyọlọ̀ yìí dáadáa, a ó rí i pé ó ṣòro láti sọ pé ẹni kan ṣoṣo ló dá tíọ́rì àbùdá onímèjì, nítorí pé gbogbo ẹ̀ka ní wọn ni ìlànà onímèjì tí wọ́n ń lò fún iṣẹ́ wọn. Ní ti lítíréṣọ̀, a lè tọpa àgbẹ̀ndé àti ìdásílẹ̀ ìmọ̀ yìí dé ọ̀dọ̀ àwọn onímọ̀ ìfojú-ìhùnwò lítíréṣọ̀. Lévi-Strauss (1972) sọ pé àwọn ènìyàn awùjọ ń gbé nínú ọ̀tẹ̀ ìhùn tí ó ní àlàfo lórí ìhùwàsí àwọn ènìyàn awùjọ. Ọ̀tẹ̀ ìhùn yìí bá ohun tí ó ní ṣe pẹ̀lú ojú méjì bí idà, gẹ́gẹ́ bí: ọ̀tún àti òsì, iwájú àti ẹ̀yìn, dúdú àti funfun. A lè fi òye ìmọ̀ ìfojú-ìhùnwò yìí wò nípa àkọ àti àbò. Lévi-Strauss rí ohun tí ó pè ní ajẹ̀mọ́ onímèjì gẹ́gẹ́ bí ohun tí Adédàà gbé ìhùn awùjọ lè, èyí sì ló bí ọ̀rọ̀ takọ̀-tàbò àti ìwọnúbọ̀nù àwọn méjèèjì nínú àṣà awùjọ. Lévi-Strauss (1972) ṣàgbékalẹ̀ tíọ́rì yìí nínú àpilẹ̀kọ rẹ̀ "The Elementary Structures of Kinship," níbi tí ó ti ṣàgbékalẹ̀ ẹbí gẹ́gẹ́ bí òpó pàtàkì tí ó gbé ìhùn awùjọ ró.

A ṣàkíyèsí pé lárí ìhùwàsí awùjọ, ìlànà àbùdá onímèjì wà, èyí ló fi jẹ́ pé tíọ́rì yìí wúlò fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀, yálà ewì, ìtàn-àròsọ tàbí eré-oníṣé. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ nípa àbùdá onímèjì ṣe jẹ́ èsọ̀ awùjọ, bẹ́ẹ̀ náà ni lítíréṣọ̀ àwùjọ náà ṣe jẹ́. Àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí gbà pé awùjọ kò le wà láìsí àbùdá onímèjì, àti pé ẹ̀yà méjì yìí ni ohun èlò tí oníṣẹ́-ònà fi ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀. Ní tori náà, lílò tíọ́rì àbùdá onímèjì fún àyẹ̀wò lítíréṣọ̀ ń jẹ́ kí ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ònà lítíréṣọ̀ túbọ̀ lọ́ọ̀rùn sí i. Bí a bá wo àgbékalẹ̀ ewì ajemẹ́ṣù, a ó rí i pé ọ̀rọ̀ nípa irúfẹ́ ẹ̀dá tí Èṣù jẹ́ ń fẹ́ àkíyèsí, pẹ̀lú ìdí tí ó fi n rìn àrin àkọ àti àbò. Èyí sì ní í ṣe pẹ̀lú àwòrán rẹ̀ àti ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó wà nínú ìpohùn rẹ̀. Nítorí náà, àwòrán èrè Èṣù jẹ́ irúfẹ́ àmi àbùdá onímèjì tó ní ìtumọ̀ tó jinlẹ̀ nínú àṣà Yorùbá. Èrò yìí náà ni Ajíbádé (2009:12) ní lọ́kàn nígbà ti ó sọ pé:

To the Yorùbá, virtually every creature in their cosmography has its complement. That is to say, even though two objects, situations, actions or reactions, ideas -seen and unseen complement each other, they are not oppositional.

(Lọ́dọ̀ àwọn Yorùbá, gbogbo Ẹ̀dá ní ó ní onígbọ̀wọ́ tirẹ̀. Èyí ni pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ nǹkan méjì, bó ṣerí, ìgbéṣẹ̀ tàbí ìṣesí, èrò-èyì tí a rí tàbí tí a kò rí ń ṣe onígbọ̀wọ́ ara wọn ni, wọn kì í ṣe àtakò ara wọn.)

Ohun tí a rí fàyọ nínú àyọlò òkè yìí ni pé gbogbo ohun tí Adẹ́dàá dá pátá yálà ènìyàn, ẹranko tàbí ohun tí a kò lè fojú rí tàbí èyí tí a kò lè fọwọ́ kàn ni wọ́n wà ní méjì méjì. Wíwà ní méjì méjì wọn kò sì wà fún láti dẹ̀yìn kọ ara wọn tàbí láti ṣe àtakò fún ara

wọn bí kò ṣe láti kọ́wọ̀ọ́rìn, kí wọn ó sì ṣe onígbọ̀wọ́ fún ara wọn. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé nínú ìfòyemọ̀ àwọn ẹ̀dá, a lè tọ́kasí ooru gẹ́gẹ́ bí ìdàkejì ọyẹ́. Ìdí ni pé, ọ̀kan yóò máa pè fún ìkejì- bí ooru bá pọ̀ ènìyàn a màa pè fún ọyẹ́. A lè rí ọyẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìdàkejì ooru. Ohun tí tíọ́rì àbùdá oníbejì fúnka mọ́ ni pé gbogbo nǹkan tí Adẹ́dàá dá ní méjì méjì yìí ni wọ́n wà fún ara wọn, wọn kì í ṣe alátakọ̀ fún ara wọn. Ọyẹ́ àti ooru, méjèèjì nì ń ṣe ọmọ ènìyàn lóore. Ìkínní sì ló jẹ́ kí a máa jẹ̀rán ìkejì.

Tíọ́rì àbùdá oníbejì ní ìlànà Ilésanmí (1988) ni a fi ṣe àtẹ̀gùn nínú iṣẹ́ yìí, nítorí pé nínú àlàyé rẹ̀ ni a ti ní òye kíkún nípa tíọ́rì àbùdá oníbejì ní ìbámu pẹ̀lú lítíréṣọ̀ àti àṣà Yorùbá. Ilésanmí (1988: 99-100) sọ pé:

Àbùdá oníbejì yìí kò fara sin rárá nínú ọ̀rọ̀ àti ìṣe Yorùbá. Kí á tó wáyé ni a ti gbà pé àbùdá oníbejì ní ipa láti kó nínú wíwá-sáyé wa. A gbọ́dọ̀ yan orí wa. A lè yan orí rere tàbí orí burúkú. Láyé pàápàá, à tètè ń gbé olobi ọmọ sin sí ipadò tàbí ojútò ni. Ọmọ jẹ́ ire, ṣùgbọ́n ibi tó bá wá sáyé ni olobi. Tọba-tìjòyè ni à ń wí, ká tó wá máa sọ̀rọ̀ tajá tẹran. Tí nǹkan bá dojúrú pátápátá a tún máa ń pe Ẹlẹ́dàá ènìyàn, èyí ni enìkejì rẹ̀ tó wà lọ́run. Bí gbogbo nǹkan ti ṣe fọwọ́kọ́wọ́ nínú ìgbésí ayé Yorùbá nìyí lórí àbùdá oníbejì.

Bí a bá wo àyọlò òkè yìí dáadáa, a ó rí i pé, gbogbo ohun tí Olódùmarè dá méjì méjì ni. Àwọn Yorùbá tilẹ̀ máa ń sọ pé "èjì lènìyàn ń rìn". Ìtumọ̀ èyí ni pé ẹnìkọ̀ọ̀kan tí Olódùmarè dá ló ní ẹnìkejì tirẹ̀. Èyí ní Yorùbá tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ẹnìkejì ẹni. Bí a bá sì ń sọ̀rọ̀ nípa tíọ́rì àbùdá oníbejì, a ó rí i pé, ohun tí ó jẹ tíọ́rì yìí lógún ni bí nǹkan ti ṣe wà ní méjì méjì. Irúfẹ́ nǹkan yìí lè kọ̀ọ̀wọ́rìn nínú ìtumọ̀ tàbí kí ìtumọ̀ wọn jẹ́ òdìkejì ara wọn. Àkíyèsí fi hàn pé àwọn ènìyàn àwùjọ máa ń fara mọ ọ̀kan nínú nǹkan méjì náà. Ó bẹ̀rẹ̀ láti orí òǹkà títí tí ó fi dé orí gbogbo ohun tí ó rọ̀ mọ́ ìgbé ayé àwọn ènìyàn àwùjọ.

**Ìdí tí a fi yan Tíọ́rì yìí láàyò**

Tíọ́rì àbùdá oníbejì ní ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ takọ-tabo. Ọ̀rọ̀ nípa takọ-tabo kò wà láṣán, ó wà lára ìhun gbogbo ètò àwùjọ pátá. Òun ló sì fi ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín àwọn ènìyàn àwùjọ hàn. Bí a bá sì wo àgbékalẹ̀ àti àkóónú ewì ajẹméṣù, a ó rí i pé, ó ní ṣe pẹ̀lú ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Ẹ̀wẹ̀, ewì ajẹméṣù tún wà fún akọ àti abo. Bí a bá sì wo ewì ajẹméṣù, a ó rí i pé akọ àti abo náà ni àwọn agbátẹ̀rù rẹ̀. **Aáyan Àwọn Ọ̀mọ̀ràn lórí Èṣù**

Ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí Èṣù. "Àbùùbùtán ẹran erin" ni iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ nípa Òrìṣà ní abala ìmọ̀. Èyí nàá ló sì fà á tí ẹ̀kọ́ nípa rẹ̀ fi fẹjú púpọ̀. Jákè-jádò àgbáyé ni àwọn onímọ̀ ti ṣiṣẹ́ lórí Èṣù nítorí pé ó jẹ́ gbajúgbajà Òrìṣà ní orílẹ̀ àgbáyé, pàápàá jù lọ láàárín àwọn Yorùbá ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti àwọn Yorùbá ilẹ̀ òkèèrè. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé orúkọ̀ tí wọ́n ń pè é ní ìlú kọ̀ọ̀kan yàtọ̀ sí ara wọn síbẹ̀ àbùdá kan náà ni ó ní jákè-jádò gbogbo àwọn ìlú ni orílẹ̀-èdè àgbáyé.

Ìdòwù (1962) ṣàlàyé pé Èṣù jẹ́ ìránṣẹ́ pàtàkì sí Olódùmarè, òun ló wà láàárín ọ̀run àti ayé. Òun sì ni ó máa ń fún Olódùmarè ní àbọ̀ gbogbo ohun tí àwọn Òrìṣà àti àwọn ọmọ ènìyàn bá gbé ayé ṣe. Gbogbo bí àwọn ènìyàn ti ṣe ṣe ayé sí, yálà nípa ìjọsìn tàbí ìrúbọ wọn sí Olódùmarè ni Èṣù máa ń ṣe àkóso rẹ̀. Ìdòwú (1962:23) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Èṣù kò dá iṣẹ́ ara rẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ tí Olódùmarè rán an ní ó máa ń jẹ́. Ó tún ṣàlàyé síwájú sí i pé:

Èṣù occupied a prominent position among the divinities. He discharged these duties without fear or favour. Thus, Èṣù is a good minister of God. He is, therefore, courted and even bribed. When such overtures fail to migrate punishment, Èṣù is then given a bad name.

(Ipò pàtàkì ni Èṣù dìmú láàárín àwọn Òrìṣà. Ó sì ń ṣe àwọn ojúṣe rẹ̀ láìbẹ̀rù àti láìṣègbè. Ìye ni pé Èṣù jẹ́ aṣojú rere sí Olódùmarè. Nítorí ìdí èyí ni àwọn ènìyàn fí máa ń wá ojú rere rẹ̀ débi pé wọn a máa fún un ní àbẹ̀tẹ́lẹ̀. Nígbà tí ìgbésẹ̀ yìí kò bá dẹ́kun ìjìyà fún wọn, wọ́n á wá fún Èṣù ní orúkọ burúkú).

Ohun tí Ìdòwú ń sọ nínú àyọlò òkè yìí ní pe ìwà tí Èṣù bá hù sì àwọn ènìyàn ni wọ́n máa fi ń fún un ní orúkọ. Bí Èṣù bá ṣe rere sí wọn, orúkọ rere ni wọ́n máa ń pè é, ṣùgbọ́n

nígbà tí ó bá ṣe búburú sí wọn, wọn a máa fún un ní orúkọ burúkú. Nítorí náà, Ìdòwú gbà pé "a-ṣe-burúkú-ṣe-rere" ni Èṣù jẹ́. Simpson (1994) tún tẹ̀ síwájú pé bí kì í bá ṣe nípa agbára Èṣù, kò sí Òrìṣà kankan tí ó lè ṣe ọmọ ènìyàn ní ibi tàbí rere. Bí àpẹẹrẹ bí Ṣàngó bá fẹ́ fí àrá pa ènìyàn, Èṣù yìí kan náà ni yóò lé iwájú láti lè jẹ́ kí aburú náà ó ṣe é ṣe. Iṣẹ Èṣù kò mọ ní èyí nìkan, ó tún lè mú kí àwọn ọ̀tá ẹni ó ṣìṣe tí wọn yóò sì fi ọwọ́ ara wọn gbẹ̀mí ara wọn. Bákan náà, Èṣù tún lè bá ni ṣe àwárí olè. Èyí túmọ̀ sí pé ojú méjì bí idà ni Èṣù ni, èyí tí ó bá sì wù ú ni ó lè kọ sí àwọn ènìyàn tàbí àwọn Òrìṣà yòókù. Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé kò sí ohun tí Èṣù kò lè bàjẹ́, ìdí nìyí tí àwọn ènìyàn fi máa ń rúbọ sí i, kí ó má baà lè ba nǹkan wọn jẹ́. Èyí ni àwọn olórin bọ̀lọ̀jọ́ máa ń fi sọ́kàn nígbà tí wọ́n bá fẹ́ ṣíde orin eré wọn. Permberton (1976:43) nínú iṣẹ́ rẹ̀ nípa Èṣù ní Ìlá-Ọ̀ràngún ṣàlàyé pé Èṣù jẹ́ Òrìṣà kan tí ó wúlò ní gbogbo ọ̀nà láwùjọ àwọn Yorùbá yàtọ̀ sí ojú alárèkérekè tí àwọn ẹ̀sìn àjèjì fi wò ó. Ó sọ pé:

It would appear, then, that in the figure of Eshu we are confronted with an orisha of the utmost importance for the domestic and religious life of the people of Ila-Orangun. How are we to understand this figure who is present in so many diverse places: at crossroads, compounds entrance, market place, king's palaces, shrines within compounds and diving sessions? The answer must be sought by first examining each of these places and situations more fully in association with the oriki, (praise names) chant at the annual festival, and with the myth preserved in the verses of Ifá, and also by analysied the descriptive iconographics features of the artefacts of Eshu worship. We shall then be in a position to ask whether the "trickster" designate for the deity".

(A ṣe àkíyèsí pé àgbékalẹ̀ àwòrán Èṣù tí a rí fi hàn pé Òrìṣà tí ó ṣe pàtàkì fún àyíká/agbègbè àti ìgbè-ayé ajẹmẹ́sìn àwọn ènìyàn Ìlá-Ọ̀ràngún ní í ṣe. Báwo ni a ṣe lè ní òye irúfẹ́ Òrìṣà yìí tí ó ń fara hàn ní onírúuru ibi gbogbo: oríta, ẹnu àbáwọ agboolé, ọjà, ààfin ọba, àwọn ojúbọ ní àárin àwọn agboolé àti àwọn ilé ìjọsìn? A ó wá ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè yìí nípa kíkọ́ wo àwọn ibi tí a mẹ́nubà yìí nípa ṣíṣe àyẹ̀wò wọn pẹ̀lú oríkì, orin tí a kọ lásìkò ọdún ìbílẹ̀, àti ìtàn- ìwáṣẹ̀ tí ó wà nínú ẹsẹ Ifá, àti nípa ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àpèjúwe àwòràn ajẹmọ́ ìjọ́sìn Èṣù. Lẹ́yìn tí a bá ṣe èyí ni a tó lè mọ̀ bóyá alárèékérekè tí wọ́n ń pe Òrìṣà yìí bá a mu).

Àlàyé Permberton (1976) jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé onírúurú ojúbọ Èṣù ló wà ní àwọn agboolé kọ̀ọ̀kan ní ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún. Àwọn onímọ̀ kan gbà pé oríṣìíríṣìí Èṣù ló wà. Àwọn kan gbà pé Èṣù méje ni ó wà, nígbà tí àwọn kan sì gbà pé ó ju bẹ́ẹ̀ lọ. Lára àwọn tí wọ́n pín Èṣù sí ìsọ̀rí ni Euba (1989). Ó pín Èṣù sí ọ̀nà mẹ́ta nípa ibi tí ó gbàgbọ́ gẹ́gẹ́ bí ibùgbé Èṣù. Àwọn ni; Èṣù oríta, Èṣù ojú ọ̀nà àti Èṣú ọjà. Nínú ìwádìí wa a rí àwọn abọrẹ̀ Èṣù bíi Olóyè Ọlágbóyèga Èṣùníyì Àkànní, baálẹ̀ Èṣù, Mọ́níyà ní Ìbàdàn ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ tí ó tako èrò yìí. Ó fi yẹ wa ẹyọ kan ṣoṣo ni Èṣù tí ó wà, orúkọ tí oníkáàlùkù ń pè é ló yàtọ̀. Èṣù Èdìtà ni wọ́n ń pe Èṣù Ìlàrẹ́ ní Ilé-Ifẹ̀, Èṣù Alájé ni wọ́n ń pe Èṣù ilé Alájé ni ìlú Ọ̀là-Èjìgbò, Ẹlẹ́gbára ni wọ́n ń pe Èṣù Ojú- Ẹlẹ́gba ni Èkó àti Ìsẹ́yìn, Òrìṣà Ìjẹ̀lú ni wọ́n ń pè é ní Ìjẹ̀lú-Èkìtì, Èṣù Baàgo ni wọ́n ń pè é ní Baàgo ní Ọ̀yọ́, Èṣù Oníyeyè ni wọ́n ń pè é ní ilé Oníyeyè ní Ọ̀yọ́, Èṣù Àwẹ̀lé, Èṣù Ìdẹ̀wùrẹ́ ni wọ́n ń pè é ní Ìbàdàn. Bákan náà ni ìwádìí fi hàn pé àwọn Èṣù kan wà tí Ifá fún lórúkọ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí wọ́n ń fi wọ́n ṣe. Bí àpẹẹrẹ Èṣù Onípọ́n-idẹ. Èyí ni Èṣù tí wọ́n fi ń ṣe ìdájọ́ láàárín ènìyàn méjì, Èṣù Agbé-ọ̀pá ọ̀run. Èyí ni Èṣù tí wọn fi ń sọ́ òde[6]. Gbogbo àwọn ibi tí wọ́n ti ń ṣawo Èṣù ni wọn ti fún un ní orúkọ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Èrò yìí ṣe déédéé pẹ̀lú èrò Peter (1997) tó ṣiṣẹ́ lórí àwọn agbègbè tí wọ́n ti ń ṣe awo Èṣù pàápàá jù lọ láwùjọ Àwórì.

Aíyejiná (2009) bu ẹnu àtẹ́ lu bí Bíṣọ́ọ̀bù Àjàyí Crowther ti ṣe yan ọ̀rọ̀ bí i; *Satan* fún ìtumọ̀ Èṣù fún àwọn Ọmọlẹ́yìn-Jésù nígbà tí ó ń túmọ̀ Bíbélì tí a kọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì sí èdè Yorùbá. Ó ní èyí kò tọ̀nà tó. Onímọ̀ yìí sì di ẹ̀bi ọ̀rọ̀ náà ru àwọn ọmọ ilẹ̀ Adúláwọ̀ pàápàá jùlọ àwọn Yorùbá tí wọ́n kò bìkítà láti kọ irúfẹ́ ìtumọ̀ náà. Wọ́n tẹ̀lé Bíṣọ́ọ̀bù Àjàyí Crowther náà láìṣe ìwádìí fínnífínní ìdí tí *Shaitan* fi lè túmọ sí Èṣù ní èdè Yorùbá. Ó tún ṣàlàyé síwàjù sí i pé bí a bá tilẹ̀ gbà pé Àjàyí Crowther ṣe àgbékalẹ̀ ìtumọ̀ rẹ̀ nítorí pé *Satan* ní

àwọn àbùdá kọ̀ọ̀kan tí ó jọ ti Èṣù, kín ló dé tí kò fi lè fi Jésù wé Ọ̀rúnmìlà nígbà tí ó jẹ́ pé àwọn méjèèjì náà ní àwọn àbùdá kan tí wọ́n fi jọ ara wọn? Dọ̀pámú (2000) kò kọ́kọ́ fi gbogbo ara mọ́ èrò Ìdòwú (1962) tí ó sọ pé Èṣù ní àbùdá kan nàá pẹ̀lú *Satan* àti *Shaitan*. Ó sọ pé a kò lè fi Èṣù Yorùbá wé Sàtání inú Bíbélì nítorí pé Èṣù kò ni ìgbìmọ̀ tirẹ̀ lọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí i ti Sàtánì. Èṣù jẹ ọ̀kan lára ìgbìmọ̀ Olódùmarè, kò sì lè dá àṣẹ tirẹ̀ pa lọ́tọ̀. Agbódegbà ni ó jẹ́ láàárín Olódùmarè àti àwọn Òrìṣà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé onímọ̀ yìí náà padà fara mọ èrò àwọn onímọ̀ yòókù nípa pé Èṣù àti Sàtánì jọ ní àbùdá kan náà, àwíjarè rẹ̀ ni pé Èṣù náà ni Sàtánì nítorí pé àwọn àbùdá burúkú tí wọn fi ròyín Sàtánì náà ló kún ọwọ́ Èṣù. Ó wá sọ ọ́ ní pàtó pé nǹkan kan náà ní Èṣù, *Satan* àti *Sahitan*. Dọ̀pámú (2000:17) tún sọ síwájú pé:

In Yorùbá belief, Èṣù is often associated with the power of evil referred to by Ìdòwù and it is in this sense that we shall regard Èṣù as we go on with our exposition of his figure, nature and character.

(Nínú ìgbàgbọ́ Yorùbá, Èṣù ní nǹkan ṣe pẹ̀lú agbára ibi tí Ìdòwú ti mẹ́nu bà á àti pé ojú yìí ni a ó fi wo Èṣù bí a ṣe ń tẹ̀síwájú láti ṣe àlàyé nípa ìrísí ìwà àti ìṣesí rẹ̀)

Ohun tí a rí fàyọ nínú àlàyé Dọ̀pámú (2000) nínú àyọlò òkè yìí fara mọ́ àbùdá tibi-tire tó gbé ìhun ayé ró.

Adékúnlé (2002) wòye pé, ó jẹ́ ohun tí ó kù díẹ̀ káàtó kí á máa fi Èṣù Yorùbá wé Sátánì tàbí kí a gbà pé gbogbo ibi/aburú tí ó bá ti ṣẹlẹ̀ láyé, iṣẹ́ ọwọ́ Èṣù ni. A kò sì gbọdọ̀ gbà pé Èṣù ni Òrìṣà fún àwọn ẹlẹ́gbẹ́ òkùnkùn bí i; osó tàbí àjẹ́ tàbí kí á ka Èṣù kún àwọn ẹ̀mí apanirun gẹ́gẹ́ bí ìwé mímọ́ àwọn Ọmọlẹ́yìn-Jésù ṣe sọ ọ́ di mímọ̀. Èrò yìí kò sí ṣẹ̀yìn gbígbé àbùdá tí kò dára fún Èṣù tí ó mú kí Bíṣọ́ọ̀bù Àjàyí Crowther ó túmọ̀ Sátánì sí Èṣù Yorùbá. Onímọ̀ yìí ṣe àkíyèsí pé lóòótọ́ àti ní òdodo Èṣù Yorùbá dà gẹ́gẹ́ bí idá olójú méjì ni. Bí ó ti ní ìwà rere bẹ́ẹ̀ náà ni ó tún ní ìwà burúkú. Ìwà burúkú yìí ni ó jẹ́ kí àwọn Ọmọlẹ́yìn-Jésù ó rí i gẹ́gẹ́ bí Sátánì inú ìwé májẹ̀mu láéláé wọn, nítorí pé wọ́n jọ ní àbùdá kan naa. Ìwé májẹ̀mu túntún awon Ọmọlẹ́yìn-Jésù gbàgbọ́ pé Sátánì ní ó máa ń dán ìgbàgbọ́ ènìyàn wò. Ṣùgbọ́n ó yẹ kí a ṣe àkíyèsí pé Èṣù Yorùbá kò tan mọ́ Sátánì tí ìwé mímọ́ Bíbélì pè ni ọ̀tá Ọlọ́run, ẹni ibi, ọta ìtẹ̀síwájú àti gbogbo ohun tó dára, ẹni tí ó dinú tí ò sì ń tako ìyè àwọn ènìyan, màdàrú ẹ̀dá tí ó kó gbogbo ìwà burúkú ayé sínú.

Adékúnlé (2002) tún ṣàlàyé pé Èṣù jẹ ẹ̀yà ènìyàn dúdú tí ó gbé ìgbé-ayé gẹ́gẹ́ bí ọkùnrin, ó sì jẹ́ àyànfẹ́ Olódùmarè, ìránṣẹ́ Ọ̀rúnmìlà àti àwọn Irúnmọlẹ̀ yòókù. Sátánì kò fi ìgbà kan gbé ìgbé ayé ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ti Èṣú. Ẹ̀mí àìrí ni Sátánì àti pé ọ̀dọ̀ àwọn òyìnbó ni ó ti gbilẹ̀ nígbà tí Èṣù Yorùbá sì ṣẹ̀ láti àwùjọ Yorùbá. Èṣù lè ní àbùdá kan náà pẹ̀lú Sátáni inú ìwé májẹmu láéláé ṣùgbọ́n kò ní àbùdá tí ó tan mọ́ Sátánì tí inú ìwé májẹ̀mu tuntun. Èṣù ní àbùdá ṣebi-ṣere ṣùgbọ́n ibi nìkan ni iṣẹ́ Sátánì. Bí a bá wá wo àríwísí onímọ̀ yìí, a ó rí i pé kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí èrò Ìdòwú (1962) àti Dọ̀pámú(2000) tí a ti ṣe àlàyé rẹ̀ ṣáájú. Ohun tí Adékúnlé (2002) fúnka mọ́ ni pé Èṣù yàtọ̀ sí Sàtánì bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n fi àwọn àbùdá kan jọ ara wọn.

Iṣẹ́ Àlàbá (2004) dá lórí oríkì Èṣù. Méjì péré nínú oríkì Èṣù ni onímọ̀ yìí túpalẹ̀. Àbájáde iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ kí a mọ̀ pé ojúṣe Èṣù tí a mọ̀ sí Láaróyè ni láti mú kí ènìyàn máa kó ara rẹ̀ ní ìjánu àti pé bí àdánwò kan bá dé bá ẹ̀dá kí irúfẹ́ ẹ̀dá náà ó ronú jinlẹ̀ kí ó tó sọ̀rọ̀ tàbí kí ó tó ṣe ìpinnu tàbí kí ó tó gbé ohun kan ṣe, kí ẹni náà ó sì jẹ́ olóòótọ́ sí ara rẹ̀ lẹ́yìn tí ó bá ti gbé ìgbéṣẹ̀ tí ẹ̀ṣan ìhùwàsí rẹ̀ bá dé. Nínú iṣẹ́ Àlàbá (2004) yìí ni a ti mọ̀ pé àwọn oríkì Èṣù gba àròjinlẹ̀ kí ìtumọ̀ wọn ó baà lè yéni yékéyéké. Bí a bá wo iṣẹ́ Àlàbá yìí, a ó rí i pé ó ti ta wá lólobó àwọn ìpèníjà tí ó wà nínú iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ lórí àkóónú àti kókó-èrò ewì ajẹméṣù. Iṣẹ́ rẹ̀ yìí sì ran ìwòye wa lọ́wọ́ nínú iṣẹ́ ìwádìí tí àwa náà fẹ́ ṣe.

Iṣẹ́ Kristen (2005) dá lórí àfiwé Èṣù láàárín àwọn ìwọ̀-oòrùn ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti ilẹ̀ òkèrè nípà ṣíṣe àyẹ̀wò orúkọ Èṣù, àwọn ibi ti wọ́n ti ń bọ ọ́, ìtàn-ìwáṣẹ̀ tí ó rọ̀ mọ́ Èṣù àti àwọn ojúbọ rẹ̀ àti àwọn ohun tí wọ́n fi ń rúbọ sí Èṣù. Àkíyèsí onímọ yìí ni pé Èṣù ni Òrìṣà "Voodoo" tí àwọn ẹ̀yà Fon/Ewe ní ilẹ̀ Idàọ̀mì ni Benin Republic ń pè ní "Lẹgba". Ó tún

ṣàlàyé lórí àwọn orúkọ tí àwọn olùsìn Òrìṣà yìí máa fi ń pè é nígbà tí wọ́n bá ń wá ojú rere rẹ̀ pẹ̀lú àfikún pé gbogbo ìlú tàbí ẹ̀yà tí ó ń bọ Èṣù ni ó ní orúkọ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n fi ń pè é ṣùgbọ́n gbogbo wọn ni wọ́n gbà pé àwùjọ Yorùbá ni ó ti wa. Kristen (2005) tún ṣe àfiwe orúkọ tí wọ́n ń pe Èṣù ní àwọn ilẹ̀ àjèjì tí ó yí ìwọ̀-oòrùn ilẹ̀ Adúláwọ̀ ká. Ó ní àwọn ìwọ̀-oòrùn ilẹ̀ Adúláwọ̀ ń pè é ní; Ẹlẹ́gbára, Ẹlẹ́gba, Eshu, Edshu àti Edju. Àwọn ilẹ̀ àjèjì ń pè é ní; Exu ni Brazil, Echu-elegua tàbí Ellegua ní ìlú Cuba àti Papa Lebat/ Papa Labas ní New Orleans. Onímọ̀ yìí tún ṣe àkàwé Èṣù pẹ̀lú àwọn Òrìṣà kan tí wọ́n jọ ń kẹ́gbẹ́ nínú ìṣesí láàárín àwùjọ òyìnbó aláwọ̀ fúnfún. Ó mẹ́nu ba Òrìṣà Hermes ní ilẹ̀ Gíríìkì; Òrìṣà Mercury ní ilẹ̀ Róòmù pé àwọn náà dà gẹ́gẹ́ bí òjíṣẹ́ láàárín àwọn Òriṣa yòókù àti láàárín àwọn Òrìṣà àti àwọn ọmọ Adáríhúnrun gẹ́gẹ́ bí Èṣù.

Ẹ̀wẹ́, Kristen (2005) tún ṣàlàyé pé oníríúurú ìlú àti àwùjọ ni wọ́n ti ń bọ Èṣù. Ìran Yorùbá sì ni ìran àkọ́kọ́ tí ó kọ́kọ́ ń bọ Èṣù nítorí pé wọ́n gbà á gẹ́gẹ́ bí àgbà láàárín àwọn Òrìṣà wọn. Láti Ilé-Ifẹ̀ ní Ìwọ̀-oòrùn orílẹ̀-èdè NÀÌJÍRÍÀ ni Èṣù ti tàn káàkiri àgbáyé. Ó tún ṣàlàyé pé nípasẹ̀ òwò ẹrú ni Èṣù fi tàn dé ìlú Fon ní ilẹ̀ Ìdàọ̀mì láàárín Ọ̀rúndún kejìdínlógún. Bákan náà, Krisen (2005) tún ṣàlàyé síwájú sí i pé àwọn ọ̀júbọ Èṣù kan wà tí ó jẹ́ ti aládàáni ní àwọn ilé kọ̀ọ̀kan láwùjọ àwọn Yorùbá. Èrò rẹ̀ yìí ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Yorùbá tó sọ pé, "Baálé ilé tí kò bá ní Ẹ́ṣù lóde abọ̀ràn Èṣù lọ́rùn". Èyí túmọ̀ sí pé gbogbo agboolé ni ó máa ń ní ojúbọ Èṣù tí wọ́n sì máa ń bọ Èṣù níbẹ̀. Bí a bá wo iṣẹ́ onímọ̀ yìí dáadáa, a ó rí ẹ̀rí àrídájú pé kárí ayé ni Èṣù gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun tí a fẹ́ ṣe iṣẹ́ lé lórí nípa Èṣù yàtọ̀ gédégbé sí ti onímọ̀ yìí síbẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀ yìí wúlò fún wa láti fi ṣe àtẹ̀gùn fún iṣẹ́ wa.

Èrò Ògúnbọ̀wálé (1980) àti Ajíbádé (2009) náà kò yàtọ̀ sí ti àwọn onímọ̀ tí a ti mẹ́nubà ṣaájú nípa pé Èṣù jẹ́ àgbà Òrìṣà, ó sì tún jẹ́ ìránṣẹ́ pàtàkì fún Olódùmarè. Èṣù ni agbódegbà láàárín Olódùmarè, àwọn Òrìṣà àti àwọn ènìyàn. Òun ní ó máa ń jíyìn iṣẹ́ ìríjú àwọn ènìyàn àti Òrìṣà fún Olódùmarè. Ajíbádé (2009:65) sọ pé:

Èṣù is the messenger, mediator, and linguist. His job is to interpret the will of the gods to man and carry man's desires to gods. These roles of Èṣù account for the interaction between him and other deities in the Yorùbá pantheon as the one that supported the person that venerates the deities through proper rituals and sacrifices. He is the one who makes sure that people follow what the diviner prescribes, and Èṣù is the one who understands the languages of diviners and clients. Therefore, he supports those that obey instructions of sacrifices.

(Èṣù jẹ́ ìránṣẹ́, agbódegbà àti agbédègbẹyọ̀. Iṣẹ́ rẹ̀ ní láti ṣògbifọ̀ ohun tí àwọn Òrìṣà fẹ́ fún ènìyàn àti gbígbé ìfẹ́ ọkàn àwọn ènìyàn lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn Òrìṣà. Àwọn Ojúṣe Èṣù yìí tó jẹ́ kí á rí ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín Èṣù àti àwọn Òrìṣà yòókù ní ilẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí alátìlẹyín fún àwọn tí wọ́n bá ṣe tí àwọn Òrìṣà nípa ṣíṣe ètùtù àti ẹbọ tí ó péye. Èṣù ni ó máa ń jẹ́ kí àwọn ènìyàn ó tẹ̀lé ohun tí Ifá bá sọ pé kí wọn ó ṣe. Èṣù sì tún ni ó gbọ́ èdè Ifá àti èdè ẹni tí ó wá dífá. Nítorí náà ó máa ń ṣègbè lẹ́yìn àwọn tí wọ́n bá gbọ́ ìkìlọ̀ ẹbọ)

Àrífàyọ wa nínú àyọlò òkè yìí fi ipò tí Èṣù wà sí Ifá hàn àti bí òun àti Ifá ti ṣe ń ṣiṣẹ́ pọ̀. Bí a bá wo iṣẹ́ onímọ̀ yìí dáadáa, a ó rí i pé, ó ta wá lólóbó pé kò sí ibòmíràn tí a lè wá ọ̀rọ̀ nípa Èṣù àti ewì rẹ̀ sí ju inú odù Ifá lọ. Èyí sì ṣe déédéé pẹ̀lú orin tí àwọn Eléṣù máa ń kọ pé:

Lílé: Taa lọ̀rẹ́ Ifá?
Ègbè: Èṣù o !
Èṣù Ọ̀dàrà
Lọ̀rẹ́ Ifá o
Èṣù o !
Lílé: Taa lọ̀rẹ́ Ifá?
Ègbè: Èṣù o !
Èṣù Ọ̀dàrà

Lọ̀rẹ́ Ifá o
Èṣù o !
(Àsomọ́ 03, orin XV, ìlà 1-10)

Ẹ̀wẹ̀, àwọn olùsìn Èṣù gbà pé àgbà Òrìṣà ni, kò sì sí Òrìṣà tí kò bá tan. Ó lágbára tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ tí ó fi jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ oore tí àwọn olùsìn rẹ̀ bá ń fẹ́ ni ó máa ń ṣe fún wọn. Èyí ni ó sì jẹ́ kí wọn ó máa sọ àwọn ọmọ wọn ní orúkọ ajẹmẹ́ṣù bí i; Èṣùbíyìí, Èṣùrónbí, Èṣùtósìn, Èṣùgbàyílà, Èṣùbámijóòkó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ògúnbọ̀wálé (1980:7) kín èrò àwọn Eléṣù yìí lẹ́yìn nígbà tí ó sọ pé:

Bí a bá ní kí á tò ó ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé, Èṣù ni igbákejì Èdùmàrè. Èṣù ni ọba àjípè. Òun kan náà ni à ń pè ní Ẹlẹ́gbára. Kí á tó bọ Ifá, kí á tó bọ Ṣàngó, a gbọ́dò júbà Ẹlẹ́gbára. Kí á tó bọ Yemọja, kí á tó bọ ìbejì, a gbọ́dọ̀ ta epo sílẹ̀ fún Èṣù.

Àkíyèsí tí a ṣe nínú àyọlò òkè yìí ni pé ìgbàgbọ́ àwọn Eléṣù nípa agbára rẹ̀ rinlẹ̀ gan-an tó fi jẹ́ pé wọ́n tilẹ̀ kà á kún igbákejì Olódùmarè. Bí a bá sì wo èrò Ògúnbọ̀wálé yìí, a ó rí i pé, ó bá ti àwọn ẹ̀yà Fon/Ewe ní ilẹ̀ Idàọ̀mì ni orílẹ̀ èdè Benin Republic mu.

Asar (2012) náà ṣiṣẹ́ lórí ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín Èṣù àti àṣẹ. Ó ṣàlàyé pé àṣẹ túmọ̀ sí ọ̀rọ̀ tí ó lágbára. Ó jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé àṣẹ ni agbára tí Olódùmarè fún Èṣù tí ó fi ń ṣe ohun tí ó bá fẹ́ yálà rere tàbí ibi. Òun náà sì ni ó fi máa ń gbé ẹbọ dọ́run. Onímọ̀ yìí ṣe àfikún rẹ̀ pé Èṣù jẹ́ ìránṣẹ́ Olódùmarè tí ó sì fi àṣẹ rẹ̀ lé e lọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bí àmì agbára rẹ̀ bí ìgbà tí ọba ìlú bá rán ọ̀kan lára àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ níṣẹ́ pẹ̀lú ọ̀pá àṣẹ rẹ̀. Ó ní gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé ọba dà bí ìránṣẹ́ Olódùmarè sí àwọn ènìyàn rẹ̀ òun náà gbọ́dọ̀ ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Èṣù tí ó jẹ́ ìránṣẹ́ Olódùmorè sí gbogbo ayé lápapọ̀. Asar (2012:9) sọ pé:

This association of Èṣù being the “messenger” is important for the aspect of àṣẹ which deals with “speech”. Èṣù is the keeper of the àṣẹ authority scepter. Èṣù is associated with a “messenger” because of the close association with word ṣe “message”in Egypt, in Yorùbá ṣẹ “do”.

(Fífi ojú wo Èṣù bí “ìráńṣẹ́” ṣe pàtàkì sí àṣẹ tí ó ní í ṣe pẹ̀lú afọ̀. Èṣù ni alákòóso àṣẹ. Èṣù ní àsomọ́ pẹ̀lú ìráńṣẹ́ nítorí ìbáṣepọ̀ tó ní pẹ̀lú ọ̀rọ̀ “ṣẹ” tí ó túmọ̀ sí “iṣẹ́” (*message*) ní èdè *Egypt*, ní ọ̀dọ̀ àwọn Yorùbá “ṣẹ” túmọ́ sí “ṣe” (*do*).

Àyọlò òkè yìí jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé àṣẹ tí ó wà ní ìkáwọ́ Èṣù yìí náà ni ó sọ ọ́ di olú láàárín àwọn Òrìṣà yòókù. Àṣẹ tí Èṣù ní yìí náà ni ó mú kí ó jẹ́ máyàmí Ọ̀rúnmìlà. Asar (2012:12) ṣàlàyé síwájú sí i pé:

Èṣù represents a moral power -the power to safe and kill; the knowledge of good and evil, the efficacy of medicine and poison, the usefulness and destructive potential of fire, water or atomic energy- and this is why Èṣù is associated with good and bad qualities and deemed “a trickster”. One's ignorance of how to handle power can blind one to reality and ultimately cause conflict in one's life. All of these attributes are represented by the -s- root and power of àṣẹ.

(Èṣù dúró gẹ́gẹ́ bí agbára tó jẹ mọ́ ìwà ọmọlúàbí -agbára láti gba ni àti láti pa; ìmọ̀ nípa rere àti ibi, ẹ̀jẹ́ oògùn àti iwọ, agbára tó wúlò àti agbára bàsèjẹ́ tí ó lè fi ba iná, omi tàbí agbára mìíràn jẹ́. Ìdí nìyí tí a fi so àbùdá síṣe búrúku síṣe rere ‘aláréékérekè'mọ́ Èṣù. Àìmọ bí wọ́n ṣe ń lo agbára lè jẹ́ kí ènìyàn má mọ ohun tó tọ́, èyí sì lè ṣe okùnfà là ásìgbò sàyé ẹni. Àwọn àbùdá wọ̀nyí ń sojú ìpìlẹ̀ṣẹ̀ agbára àṣẹ.

Fálọlá (2013) náà ṣiṣẹ́ lórí Èṣù. Ojú tí onímọ̀ yìí fi wo Èṣù kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ti àwọn onímọ̀ ìṣáájú tí a ti mẹnubà. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé ó ṣe àfihàn Èṣù gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà tí ó kárí ayé. Nínú àlàyé ọ̀rọ̀ rẹ̀, ó wo Èṣù gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà A-jà-má-mọ-àlà tí ó sì lágbára A-ṣẹ̀-má-bi. Bákan náà, ó tún jẹ Òrìṣà tí ó ní ìbátan pẹ̀lú gbogbo àwọn Òrìṣà yòókù. Èyí ló jẹ́ kí ó jẹ́ gbajúgbajà Òrìṣà ní orílẹ̀ àgbáyé. Fálọlá (2013) tún sọ àsọyán nínú àlàyé rẹ̀ pé Èṣù ni agbódegbà láàárín Olódùmarè àti àwọn ọmọ adáríhunrun. Oun sì ni ó máa ń jẹ́ kí ìfẹ́ inú ẹni ó se.

Onímọ̀ yìí ṣe àfikún rẹ̀ pé Èṣù ni asọ́bodè tí ó máa ń sọ ẹnu ìloro tó kángun sí ayé àti ọ̀run nítorí rẹ̀ ni ó ṣe múlé rẹ̀ sí oríta mẹ́ta tí ń dààmú onílé àti àlejò. Fálọlá (2013) tún sọ pé a lè wo Èṣù gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà A-lá-rèké-n-dá tí ó ní oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ tí ó lè fi mú ọmọ ènìyàn ṣíwàhù tí yóò sì kọ́ wọn lẹ́kọ̀ọ́. Ó ṣàlàyé pé 'àṣẹ' ni agbára tí Olódùmarè fún Èṣù tí ó fi ń darí ohun gbogbo tí ó bá fẹ́. Onímọ̀ yìí wá fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àpèjúwe Èṣù fara pẹ́ bí ayé ṣe rí gẹ́lẹ́. Ó sọ pé, ''Èṣù represents the balance of nature. Day and night, white and black, construction and deconstruction. Èṣù is an old man and a child. Absolute balance of nature (Fálọlá 2013 :10) ''. (Èṣu dúró gẹ́gẹ́ bí òṣùnwọ̀n dọ́gbandọ́gba bí ayé ṣe rí. Ọjọ́ àti òru, funfun àti dúdú, ìhunpọ̀ àti ìfọ́síwẹ́wẹ́. Arúgbó ni Èṣù, ọmọdé sì ni pẹ̀lú. Àbùdá òṣùnwọ̀n báyé ṣe rí gan-an).

Iṣẹ́ Onyibor àti Eégúnlúsì (2019) dá lórí èrò àti ìgbàgbọ́ ẹ̀yà Ìgbò àti Yorùbá nípa Ire ati Ibi. Àkíyèsí àwọn onímọ̀ yìí fi hàn pé èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn ẹ̀yà méjèèjì yìí jọra lórí ohun tí ó máa ń ṣe okùnfà ibi. Wọ́n wá ṣàlàyé pé lára àwọn ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ pé ó máa ń ṣe okùnfà ibi ni; ìpín, iṣẹ́ ọwọ́ Èṣù Ẹlẹ́gbára, iṣẹ́ ọwọ́ Ọlọ́run àti iṣẹ́ ọwọ́ àwọn Àjẹ́. Bí a bá wo èrò àwọn onímọ̀ yìí nípa pé lára ọ̀nà tí 'ibi' máa ń gbà ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀dá ni iṣẹ́ ọwọ́ Ọlọ́run, a ó rí i pé èyí tako èrò àwọn ẹlẹ́sìn Ọmọlẹ́yìn-Jésù tí wọ́n gbàgbọ́ pé Ọlọ́run kì í ṣe 'ibi', tí wọ́n sì máa ń fi hàn nínú ìpèdè wọn pé "rere ni Olúwa, Ọlọ́run ò ṣebi, rere ló ń ṣe". Bí a bá sì wo èrò àwọn ẹlẹ́sìn Ìsìláàmù náà, wọ́n gbà pé ohun gbogbo láti ọwọ́ Ọlọ́run ni ó ti wá. Àwọn onímọ̀ yìí fi èrò Onyibor àti Eégúnlúsì (2019) ṣàlàyé síwájú sí i pé, "Èṣù is seen as a powerful deity with whom different types of evil can be associated (Onyibor àti Eégúnlúsì 2019: 2)". (Èṣù ni a rí gẹ́gẹ́ bí alágbára Òrìṣà tí oríṣìíríṣìí ẹ̀yà ibi so mọ́). Bí a bá wo èrò àwọn onímọ̀ yìí, a ó rí i pé èrò àwọn onímọ̀ yìí "rólé apá kan dákan sí". Ìdí ni pé ṣebi-ṣere ni Èṣù gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ tí a ti mẹ́nubà tẹ́lẹ̀ ti ṣe sọ, bí o tílẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ yìí gbà pé gbogbo àwọn Òrìṣà náà ló lágbára láti ṣe ibi fún ọmọ ènìyàn.

Ohun tí à rí fàyọ nínú iṣẹ́ wọ́n ni pé ibi àti ire jẹ́ kòṣeémánìí fún àwùjọ àti wí pé ibi àti ire kì í déédéé wá bí kò ṣe nípasẹ̀ ìpín, iṣẹ́ ọwọ́ Ọlọ́run, Èṣù, Àjẹ́ àti àwọn ẹ̀mí àìrí yòókù. Àwọn onímọ̀ yìí ṣe àlàyé síwájú sí i pé gbogbo ibi tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀dá láti ọwọ́ Èṣù ni ó ti wá. Àwa kò sì fi gbogbo ara gba èyí gbọ́. Ohun tí a tún ṣàlàyé nínú iṣẹ́ wọn ni pé wọ́n gbà Èṣù gẹ́gẹ́ bí agbódegbà láàárín Olódùmarè àti àwọn Òrìṣà yòókù. Gbogbo ibi tí wọ́n bá sì fẹ́ ṣe dandan ni kí wọn ó fi ti Èṣù ṣe. Ohun tí ó jẹ wa lógún nínú iṣẹ́ yìí ni wí pé àwọn àbùdá Èṣù tí àwọn onímọ̀ yìí ṣàlàyé ṣe ìrànlọ́wọ́ fún iṣẹ́ wa púpọ̀.

Igboin (2019) pín Èṣù àti Olódùmarè sí mẹ́rin nínú iṣẹ́ rẹ̀. Ìpínsísọ̀rí rẹ̀ yìí gbára lé èrò àti ìgbàgbọ́ àwùjọ nípa Èṣù àti Olódùmarè. Ìpín kìn-ín-ní ló pè ní Èṣù àti Olódùmarè ní ti ìlànà ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìpín kejì ni Èṣù àti Olódùmarè ní ti ìlànà àwọn Yorùbá tí wọ́n jẹ́ ẹlẹ́sìn Ọmọlẹ́yìn-Jésù. Ìpín kẹta ni ó pè ni Èṣù àti Olódùmarè ní ti ìlànà àwọn ọmọ Yorùbá tí wọ́n jẹ́ ẹlẹ́sìn Ìsìláàmù, nígbà tí ó pe ìpín kẹrin ní Èṣù àti Olódùmarè tó jẹmọ́ ìmọ̀ èrò-ìjìnlẹ̀. Igboin (2019) tún ṣàlàyé pé Èṣù àti Olódùmarè Yorùbá kì í ṣe alátakò ara wọn nítorí pé iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè ni Èṣù. Ó sì tún jẹ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn òjíṣẹ́ Olódùmarè. Igboin (2019:224) sọ pé:

> The traditional Olódùmarè, being a good Being could not have entrusted so much to the traditional Èṣù if he was as bad as people believed he was. The fact remains that the traditional Olódùmarè is seen as a good and perfect Being who cannot create evil. Since he created Èṣù, thus, the divinity cannot be evil.

(Olódùmarè dára ju kí ó fi ọkàn tán Èṣù lọ tó bá jẹ́ pé Èṣù jẹ́ Òrìṣà burúkú gẹ́gẹ́ bí èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn kan. Ohun tó wà níbẹ̀ ni pé, Olódùmare dára, Ó sì pé ju ki Ó wá ṣẹ̀dá ibi lọ. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé Òun náà ló dá Èṣù, nítorí náà, Èṣù kò lè jẹ́ Òrìṣà búrurú.)

Èrò òkè yìí fi hàn pé Èṣù ìbílẹ̀ Yorùbá yàtọ̀ sí Èṣù ti àwọn Ọmọlẹ́yìn-Jésù àti àwọn ẹlẹ́sìn Ìsìláàmù tọ́kasí gẹ́gẹ́ bí ọ̀tá Olódùmarè nínú ìwé wọn. Ohun tí à rí fàyọ nínú àwíjàre Igboin (2019) jẹ́ kí a mọ̀ pé àbùdá aṣebukúrú tí Sàtánì àti Sheitan ti àwọn ẹlẹ́sìn Ọmọlẹ́yìn-Jésù àti Ìsìláàmù ní, ló jẹ́ kí wọ́n ó pé è ní ọ̀tá Ọlọ́run. Ohun tí ó jẹ wa lógún nínú iṣẹ́ yìí ni wí pé àwọn àbùdá Èṣù tí àwọn onímọ̀ yìí yóò wúlò púpọ̀ fún iṣẹ́ wa.

Àkíyèsí fi hàn pé ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí Èṣù, ṣùgbọ́n bí àwọn onímọ̀ yìí tipọ̀ tó, a kò tíì ri iṣẹ́ nípa àgbékalẹ̀ àti àkóónú ewì ajẹméṣù. Nítorí náà, àgbékalẹ̀ àti àkóónú ewì ajẹméṣù tí iṣẹ́ yìí dá lé ṣe àfikún ìmọ̀ nípa ewì ajẹméṣù àti lítíréṣọ̀ alohùn ajẹmọ́rìṣà lápapọ̀.

Àbájáde iṣẹ́ Saadu (20021) lórí àgbékalẹ̀ àti àkóónú ewì ajẹméṣù fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn àwùjọ rọ̀ mọ́ agbára ṣebi-ṣere tí Adẹ́dàá fi fún Èṣù Ọ̀dàrà. Ìdí sì nìyí tí gbogbo àwọn Irúnmọlẹ̀ àti àwọn ọmọ ènìyàn fi máa ń wárí fún un, tí wọ́n sì máa ń fi tirẹ̀ ṣe kí ó má baà dà wọn lọ́bẹ̀ tó dùn nù. Iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ tún ṣàlàyé ipa pàtàkì tí ewì ajẹméṣù kó nínú ìmúgbòòrò bá àwùjọ. Ohún kan pàtàkì tí onímọ̀ yìí ṣe àkíyèsí níbí yìí ni pé Èṣù àti Ọrúnmìlà jẹ́ ọ̀rẹ́ ìmùlẹ̀. Èyí náà sì ló dífá fún gbogbo àwọn babaláwo tí wọ́n fi jẹ́ agbátẹrù Èṣù. Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe mọ̀ pé ọ̀rọ̀ tí ó bá ń dun onísègùn níí dun Ọ̀sanyìn, ọ̀rọ̀ tí ó ń dun Ifá ní ń dun babaláwo. Gbogbo ohun tó bá ní í ṣe pẹ̀lú Èṣù, kò sí ibi méjì tí a lè wá a sí tayọ ọ̀dọ̀ àwọn abọrẹ̀ Èṣù àti ọ̀dọ̀ àwọn babaláwo.

**Àfihàn Agbára Èṣù Nínú Ewì Ajeméṣù**

Èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé kò sí Òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá kan tí kò ní agbára àdámọ́ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Agbára àdámọ́ yìí ni àwọn olùsin wọn fi gbà wọ́n ní ìbọ, aláfẹ̀yìntì, agbẹ̀bọdọ́run tàbí alàgàta láàrin wọn àti Olódùmarè. Bí àpẹẹrẹ, Ṣàngó ni Adẹ́dàá fún ní agbára àdámọ́ iná àti àrá. Òjò àti afẹ́fẹ́ ni ti Ọya. Omi ni agbára àdámọ́ tí Olódùmarè fún Ọ̀ṣun. Bí àwọn Òrìṣà yìí ti ṣe ni agbára láti ṣe ire bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n ṣe ni agbára láti ṣe ibi. Ṣùgbọ́n ó dàbí ẹni pé ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn gbà pé Èṣù nìkan ni Adẹ́dàá fún ní agbára ṣebi-ṣere. Ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn Èṣù ni wí pé Òrìṣà alágbára ni.

Ó sì lè ṣe ohunkóhun tí wọ́n bá fẹ́ fún wọn. Bí àwọn babaláwo ṣe ní ìgbékẹ̀lẹ́ nínú agbara Ifá tó, bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n tún ni ìgbàgbọ́ nínú agbára Èṣù. Bi àwọn Mọ̀gbà náà ti ṣe ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú agbára Ṣàngó bẹ́ẹ̀, náà ni wọ́n tún ń fi ti Èṣù ṣe nítorí agbára rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onísẹ̀gùn ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú agbára Ọ̀sanyìn, síbẹ̀ àwọn náà nígbàgbọ́ nínú agbára Èṣù. Èyí túmọ̀ sí pé kò sí Òrìṣà tí kò gba Èṣù ní alágbára.

Agbára tí Èṣù ní yìí ló fún àwọn olùsìn rẹ̀ ní ìgbékẹ̀lé nínú rẹ. Wọ́n gbàgbọ́ pé Èṣù lágbára láti sọ àgàn di ọlọ́mọ. Ìdí nìyí tí àwọn obìnrin tí kò bá rí ọmọ bí ṣe máa ń rawọ́rasẹ̀ sí Èṣù fún ọmọ lásìkò ọdún Èṣù. Bí wọ́n bá sì bímọ ọ̀hún tán wọn a sì sọ ọmọ náà ní orúkọ̀ ajẹméṣù. Bí àpẹẹrẹ, wọn lè sọ irú ọmọ bẹ́ẹ̀ ní Èṣúsèyí, Èṣùbiyi tàbí Èṣùgbèmí. Èyí sì máa ń fara hàn nínú ewì Èṣù. Bí a bá fi ojú àbùdá oníbejì wò ó, a ó rí i pé ojú méjì náà ni a lè fi wo àfihàn agbára Èṣù. A rí ibi tí Èṣù ti ṣe rere àti ibi. Bí àpẹẹrẹ, Eléṣù kan fi Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà tó lágbára tí ó sì lè sọ àgàn di ọlọ́mọ nínú ìpohùn rẹ̀ báyìí pé:

Barákéré
Baba ọlọ́mọyọyọ
Àgàn tí ò rí bí
Barákéré ni ò dáhùn sí i
Ọpẹ́ àwa èsín la mú wá
Èṣùṣèyí Irúnmọlẹ̀ gbẹ́bẹ̀ mi

Ohun tí àyọlò ewì Èṣù òkè yìí fi hàn ni pé Èṣù jẹ́ Òrìṣà alágbára tí ó sì lè sọ àgàn tí kò rí ọmọ bí di ọlọ́mọ. Ìlà kínní sí ìlà kejì fi Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí bàbá ọlọ́mọ-yọyọ tí àwọn olùsìn rẹ̀ máa ń rawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí fún ọmọ. Ìlà kẹta sí ìlà kẹrin nínú àyọlọ̀ yìí sọ ọ́ ní pàtó pé àyàfi àgàn tí kò bá fi ti Èṣù ṣe ni ó lè sọ pé òun kò rí ọmọ bí. Èyí túmọ̀ sí pé nínú agbára tí Olódùmarè fi kẹ́ Èṣù ni kí ó sọ àgàn di ọlọ́mọ. Akéwì yìí wá jẹ́rìí sí agbára Èṣù pé ọmọ tí àwọn tọrọ lọ́dọ̀ Èṣù ní ọdún tí ó kọjá ni àwọn gbé wá sí ọ̀dọ̀ Èṣù ní ọdún yìí. Nígbà tí ó sọ pé "ọpẹ́ àwa èsín la mú wá, "Èṣùṣèyí irúnmọlẹ̀ gbẹ́bẹ̀ mi" ní ìlà karùn-ún sí ìlà kẹfà. Ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn Èṣù nípa agbára rẹ̀ yìí gbára lé ìgbàgbọ́ àwùjọ tí ó ṣe àfi hàn gbogbo ìbọ àti ìjọsìn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti bá Olódùmarè sọ̀rọ̀ àti láti bèèrè fún ohun tí wọ́n bá ń fẹ́ lọ́dọ̀

Olódùmarè. Ìgbàgbọ́ àwùjọ yìí náà ni àwọn apèṣù ni lọ́kàn nígbà tí wọ́n bá ń tipasẹ̀ Èṣù wá ojú rere Olódùmarè.

Ẹ̀wẹ̀, ọ̀pọ̀ ìtàn-ìwáṣẹ̀ láti inú ẹsẹ Ifá ló fi hàn wá pé Èṣù ọ̀dàrà máa ń lo agbára rẹ̀ láti fi ran Ọ̀rúnmìlà lọ́wọ́ kí èrò rẹ̀ ó wá sí ìmúṣẹ ní. Ọ̀pọ̀ ìgbà sì ni Ọ̀rúnmìlà náà máa ń tọ Èṣù ọ̀dàrà lọ fún Ìrànlọ́wọ́ nígbà tí agbára rẹ̀ kò bá ka nǹkan tí ó fẹ́ ṣe. Bí àpẹẹrẹ, Odù Ifá *Òtúrúpọ̀n Méjì* tí ó lọ báyìí pé:

Òtúrúpọ̀n jẹ́bọ ó fín
Òtúrúpọ̀n jẹ́bọ ó dà
A díá fún Ọ̀rúnmìlà
Ifá ń fi omijé ṣe ìráhùn ire gbogbo
Ọ̀rúnmìla kò rí oókan ààyọ́ná
Ifá kò ní eéjì àdìbò
Ọ̀rúnmìlà kò ní ẹ́ẹ́ta ìtẹ́ní
Ifá ń wá ire owó
Ọ̀rúnmìlà ń wá ire aya
Ó ń wá ire gbogbo
Wọ́n kí ó káakí mọ́lẹ̀
Ẹbọ ni wọ́n ní kí ó ṣe
Wọ́n ní kí ó rúbọ fún Èṣù Ọ̀dàrà
Wọ́n ní Èṣù Ọ̀dàrà ni yóò gbé e pọ̀n débi ire rẹ̀ gbé wà
Ọ̀rúnmìlà rúbọ fÉṣù…
Ijó ní í jó
Ayọ̀ ní í yọ̀
Ó yanu kótó orin awo ló kó sí i lẹ́nu
Ẹsẹ̀ tí ó nà
Ijó fà á
Ó ní:
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadaa
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadaa
Ò bá pọ̀nmí sówó kí o pọ̀n mí sọ́rọ̀
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadaa

A ó rí i pé olùrànlọ́wọ́ ni Èṣù jẹ́ sí Ọ̀rúnmìlà níbí. Ìtàn inú ẹsẹ Ifá yìí sọ bí Èṣù Ọ̀dàrà ti ṣe pọn Ọ̀rúnmìlà dé ibi ti ire rẹ̀ wà. Ìtàn inú àyọlò Ifá òkè yìí jẹ́ kí ó yé wa pé, ojú ire gbogbo ló ń pọ́n Ọ̀rúnmìlà nígbà ìwáṣẹ̀. Nígbà tí àwọn babaláwo rẹ̀ sì dá Ifá fún un, Òtúrúpọ̀n méjì ni odú Ifá ti ó yọ sí i lójú ọpọ́n Ifá. Wọ́n ní kí ó rúbọ fún Èṣù Ọ̀dàrà pé Èṣù ni yóò gbé e dé ibi tí ire rẹ̀ wà. Ọ̀rúnmìlà rúbọ fún Èṣù, Èṣù sì pọn Ọ̀rúnmìlà débi tí owó wà. Ọ̀rúnmìlà bá fi orin Ifá bọnu báyìí pé:

Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,
Ò bá pọ̀n mí sówó,
Kí o má pọ̀n mí síyà,
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa.

Bí Ọ̀rúnmìlà ti ṣe ń kọrin yìí bẹ́ẹ̀ ni Èṣù Ọ̀dàrà kò sọ̀ ọ́ kalẹ̀. Èṣù tún pọn Ọ̀rúnmìlà débi ti ire aya wà, Ọ̀rúnmìlà fi orin Ifá bọnu. Èṣù Ọ̀dàrà kò tún sọ Ọ̀rúnmìlà kalẹ̀. Èṣù Ọ̀dàrà tún pọn Ọ̀rúnmìlà dé ibi tí ire ọmọ wà, Ọ̀rúnmìlà tún fi orin Ifá bọnu. Ó tún ní:

Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,

Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,
Ò bá pọ̀n mí sówó,
Kí o má pọ̀n mí síyà,
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,

Èṣù Ọ̀dàrà tún pọ̀n Ọ̀rúnmìlà débi tí ire ọmọ wà. Kò tún sọ Ọ̀rúnmìlà kalẹ̀. Ọ̀rúnmìlà tún fi orin bọnu. Èṣù Ọ̀dàrà kò tún dá Ọ̀rúnmìlà lóhùn. Èṣù tún pọ̀n ọ́n dé ibi tí ire gbogbo wà, kò tún sọ̀ ọ́ kalẹ̀. Ọ̀rúnmìlà tún fi orin Ifá bọnu, ó tún ní:

Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,
Ò bá pọ̀n mí sówó,
Kí o má pọ̀n mí síyà,
Èṣù Ọ̀dàrà pọ̀n mí dáadáa,

Èṣù tún kọ̀ kò sọ Ọ̀rúnmìlà kalẹ̀. Nígbà tí Èṣù pọn Ọ̀rúnmìlà dé ibi tí sùúrù wa ni ó tó sọ̀ ọ́ kalẹ̀. Ni Ọ̀rúnmìlà bá banújẹ́. Ó sọ pé ṣebí “Èṣù tí wọ́n pé yóò gbé òun dé ibi tí ire òun wà náà kọ́ ni ó ti gbé òun kọjá gbogbo ire tí òun ń fẹ́ yìí? Bẹ́ẹ̀, òun sì tọ́jú Èṣù dáadáa”. Ọ̀rúnmìlà rò pé ṣe kì í ṣe pé ìyà ni Èṣù fẹ́ fi jẹ òun báyìí. Èṣù Ọ̀dàrà bá lọ bá owó níbi tí ó wà, ó sì sọ fún owó pé kí ó máa lọ síbi tí sùúrù wà. Ó tún lọ bá aya, ó sọ pé ibi tí ó wà yìí kì í ṣe ààyè rẹ̀ pé kí ó máa lọ sí ibi tí sùúrù wà. Ó tún lọ bá ọmọ ó ní kí òun náà ó máa lọ sí ibi tí sùúrù wà. Ó tún kúrò níbẹ̀, ó tún lọ bá ire gbogbo. Ó ní ki òun náà ó máa lọ sí ibi ti sùúrù wà. Ní Ọ̀rúnmìlà bá ń jó ni ó bá ń yọ̀, ni ó bá di oníre gbogbo.

Bí a bá wo ìtàn ajẹmẹ́ṣù òkè yìí, a ó rí i pé, oore ńlá gbáà ní Èṣù Ọ̀dàrà ṣe fún Ọ̀rúnmìlà níbí. Èṣù dúró gẹ́gẹ́ bí ọ̀rẹ́ òtítọ́ fún Ọ̀rúnmìlà níbí. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé, Ọ̀rúnmìlà kò mọ̀ pé oore ni Èṣù fẹ́ ṣe fún òun. Nítorí pé Èṣù gbé e kọjá àwọn ire gbogbo tí ó ní lọ́kàn, tí ó sì wá sọ̀ ọ́ kalẹ̀ sí ilé sùúrù. Gbogbo ire tí o tí gbé e kọjá wá padà bá a láìdààmú rárá. Bí a bá wo àwùjọ wa, ọ̀pọ̀ ènìyàn ni irú iṣẹ̀lẹ̀ yìí máa ń ṣẹlẹ̀ sí, tí ó jẹ pé wọ́n lè má kọ́kọ́ mọ̀ pé ire ni gbogbo ohun tí àwọn ń ṣe, tí wọn yóò sì lérò pé ibi ni, ṣùgbọ́n tí wọn yóò padà rí i pé ire ni nígbẹ̀yìn. Èyí sì ṣe déédéé pèlú èrò ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá tí ó sọ pé “bí oore bá fojú jọ ibi, ẹ̀dá yóò máa bínú”.

Ẹ̀kọ́ ńlá tí ewì ajẹmẹ́ṣù yìí ń kọ́ àwùjọ ni pé kí a máa ní sùúrù nítorí pé sùúrù ni baba ìwà, ìwà sì ni baba àwúre. Ẹni tí yóò bá sì là, tí yóò lu láyé, ó gbọ́dọ̀ di sùúrù mọ́ ẹrù rẹ̀ nítorí pé ilé sùúrù ni owó, ọmọ, aya àti ire gbogbo ń gbé. Ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé àwọn ènìyàn kò fẹ́ ní sùúrù mọ́ ní ayé òde òní. Aré owó ni gbogbo wọn ń sá. Ìdí nìyí ti ikú ọ̀dọ́ àti ìwà burúkú bí i; ká gbọ́mọ ṣẹ́ṣọ́, ìwà ìgbésùnmọ̀mí, ká jínigbé-bèèrè-fún-owó àti ìwà ọ̀daràn lóríṣiíríṣìí fi kún àwùjọ wa. Nítorí náà, ọ̀nà kan pàtàkì láti pàrọwà sí àwùjọ ni irúfẹ́ ewì ajẹmẹ́ṣù yìí jẹ́.

A tún ṣe àkíyèsí àpẹẹrẹ àfihàn agbára Èṣù mìíràn nínú ewì ìsàlẹ̀ yìí tí ó fi Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà alágbára tí ẹnìkankan kò lè ṣe ohunkóhun láìfi tiẹ̀ ṣe. Apèṣù kan sọ pé:

Èṣù ń ṣe ọ́
O ní ò ń bỌ̀ṣun
Láàlú ń ṣe ó
O ní ò ń bÒòṣà
O ò bá à bÒòṣà
Kí o bọ Ọbàtálá
Ó di bó o bá tọ́po sí Ẹlẹ́gbára
Kó tó jú ọ ọ́ ṣe
Ológún ẹrú rúbọ kÉṣù má ṣe é
Ábòǹtórí ọlọ́gbọ̀n ìwọ̀fà

Nínú àyọlò òkè yìí, akéwì fi agbára Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí àgbà Òrìṣà tí ó sì ní agbára débi wí pé kò sí ohun tí ènìyàn lè ṣe láìfi tiẹ̀ ṣe tí nǹkan ọ̀hún yóò júṣe. Ìdí nìyí ti akéwì fi tọ́ka sí i ní ìlà kìn-ín-ní sí ìlà keje pé ẹni tí Èṣù bá ń ṣe kò sí Òrìṣà tí ó lè bọ tí ọ̀rọ̀ rẹ̀ yóò fi lójúùtú àyàfí tí ó bá tapo lé Ẹlẹ́gbára lórí kí ọ̀rọ̀ irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ó tó ní ojúùtú. Bí a bá wo ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn Èṣù nínú àyọlò òkè yìí a ó rí i pé ó ṣe déédéé pẹ̀lú ojú àmúwayé Yorùbá tí ó máa ń hàn nínú ọ̀rọ̀ wọn pé “ẹni tí ó mọ ojúso okùn ni yóò mọ àtitú u”.

Yorùbá gbàgbọ́ pé Èṣù ní agbára oró. Èyí túmọ̀ sí pé Èṣù lè dá ènìyàn lóró. Dídá lóró níbí yìí kì í ṣe nípa ikú nìkan, ó lè ba iṣẹ́ ènìyàn jẹ, tí yóò sì da ìkorò sí adùn ayé ènìyàn. Ó sì tún lè dá ìjà sílẹ̀ láààrín ọ̀rẹ́ méjì. A rí àpẹẹrẹ àfihàn irú agbára yìí nínú àyọlò ewì Èṣù ìsàlẹ̀ yìí. Akéwì Èṣù fi hàn gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà alágbára tí àwọn ènìyàn máa ń bẹ̀rù nítorí pé ó ní agbára dàrú-dàpọ̀. Ó lè dá ìjà sílẹ̀ láàrìn àwọn ọ̀rẹ́ ìmùlẹ̀ méjì. Ó sì ní agbára láti tapo sí ìjà. Wọ́n tilẹ̀ máa ń kọrin kan tí àwọn méjì bá ń jà pé:

Lílé: Èṣù tapo sí i
Èṣù tapo sí i
Kí ìwọ ó lè jà
Kí èmi ó lè wòran
Èṣù tapo sì i
Ègbè: Èṣù tapo sí i
Èṣù tapo sí i
Kí ìwọ ó lè jà
Kí èmi ó lè wòran
Èṣù tapo sì i

Àyọlò òkè yìí fi Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà tó lágbára láti dá ìjà sílẹ̀ ní ààrin àwọn ènìyàn méjì. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé bí ènìyàn méjì bá ń bá ara wọn jà, Èṣù tapo sí ààrin wọn ni. Gbogbo ibi tí ìjà bá ti ṣẹlẹ̀, wọ́n gbà pé Èṣù wà níbẹ̀ ni. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé “ẹ má gba Èṣù láàyè” nígbà tí wọ́n bá rí i pé ààrin àwọn méjì tí ó yẹ kí ó gún, kò gún mọ́.

A tún ri ibi ti Èṣù ọ̀dàrà ti tún lo agbára rẹ̀ láti ṣe Ọ̀rúnmìlà ní ibi nígbà mìíràn. Èyí fi agbára ṣebúrúkú-ṣerere Èṣù hàn. Bí àpẹẹrẹ, a rí ibi tí Èṣù ti yá Ọ̀rúnmìlà ní ‘orí’ tí Èṣù sì fẹ́ fi ayé sú Ọ̀rúnmìlà lẹ́yìn náà. A rí èyí nínú Odù Ifá *Ogbè Ìyọ̀nú* (Ogbè lọ̀tùn-ún Ògúndá lósì) tí babaláwo Ifátáyọ̀ Ọ̀jẹ́dìran ní ilé Ọbádọ̀fin, Ògbómọ̀ṣọ́ kì fún wa báyìí pé:

Bí orí wọn ò bá sunwọ̀n
Orí olórí ni wọ́n máa ń yá rebi
A díá fún Ọ̀rúnmìlà’
Ifá ó rè é yá orí Èṣù Ọ̀dàrà joyè
…
Ó ní; Ẹ̀ṣù Ọ̀dàrà sìn lẹ́yìn mi o
Èṣù Ọ̀dàrà sìn lẹ́yìn mi
Gboríġborí kan kì í
Gborí ẹ̀ẹmejì
Èṣù Ọ̀dàrà sìn lẹ́yìn mi

Ìtàn inú ẹsẹ Ifá òkè yìí jẹ́ kí ó di mímọ̀ bí Ọ̀rúnmìlà ti ṣe lọ yá orí lọ́wọ́ Èṣù Ọ̀dàrà. Fìlà ni wọ́n ń pè ní ‘orí’ nígbà ìwáṣẹ̀. Èṣù yá Ọ̀rúnmìlà ní orí tán. Ni ó bá di pé Ọ̀rúnmìlà bẹ̀rẹ̀ sí í gbayì káàkiri ayé. Àìní ìfẹ́ Ọ̀rúnmìlà dénú ló jẹ́ kí Èṣù ó yarí pé òun fẹ́ gba orí òun padà. Nígbà tí ó padà wá bá Ọ̀rúnmìlà ni Ọ̀rúnmìlà bá sọ fún un pé òun kò lè fi orí yìí sílẹ̀ mọ́ pé kí ó jẹ́ kí òun ó fi orí orúkọ dípò. Ní Ọ̀rúnmìlà bá fún Èṣù ní orí ‘itú’ kan. Lẹ́yìn tí ilẹ̀

tún ta sí i díẹ̀ ni Èṣù bá tún padà wá pé ki Ọ̀rúnmìlà ó bá òun gbé orí òun. Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà rí i pé Èṣù ti fẹ́ yọ ilé ayé lẹ́mìí òun ni ó bá fi orin bọnu pé:

Èṣù Ọ̀dàrà sìn lẹ́yìn mi o,
Èṣù Ọ̀dàrà sìn lẹ́yìn mi,
Gborígborí kan kì í gborí lẹ́ẹ̀mejì,
Èṣù Ọ̀dàrà sìn lẹ́yìn mi.

Ìtàn Ifá yìí jẹ́ kí ó yé wa pé bí Èṣù bá gbé wàhálà rẹ̀ dé, Ọ̀rúnmìlà gan-an a máa fẹ́ bọ́hùn tí kò ni lè ni sùúrù láti mú un mọ́ra mọ́.

Èṣù gẹ́gẹ́ bí elénìní Ọ̀rúnmìlà ni a tún rí nínú Dọ̀pámú (2000: 119-120) níbi tí Èṣù tun ti pàdé Ọ̀rúnmìlà níbi tí ó ti ń lọ fi ẹjọ́ ọmọ aráyé sùn Olódùmarè pé wọn kò moore. Èṣù tẹ̀lé Ọ̀rúnmìlà lọ sí ìkọ̀lé ọ̀run. Ó sì mú nínú àtòrì tí ó kó lọ́wọ́, ó bẹ̀rẹ̀ sí fi na àwọn ọmọ aráyé tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ tí wọ́n fi sáré lọ sí abẹ́ ààbò Olódùmarè. Olódùmarè bi Ọ̀rúnmìlà pé kín ní ó fà á tí Ọ̀rúnmìlà kò fi lè dáàbò bo àwọn ẹ̀dá aráyé tí Òun kó sí abẹ́ ìṣọ́ rẹ̀, Ọ̀rúnmìlà ní Èṣù náà ló ń dá gbogbo wàhálà sílẹ̀ fún ọmọ aráyé àti pé ara irú wàhálà náà ni Olódùmarè fojú rí yẹn. Olódùmarè bá pa á láṣẹ pé Ọ̀rúnmìlà kò gbọ́dọ̀ mú Èṣù wá sódè ọ̀run mọ́ ṣùgbọ́n kí Ọ̀rúnmílà máa mójú tó gbogbo ẹ̀dá aráyé. Bí a ba tẹ̀lé èrò yìí, a ó rí i pé Èṣù jẹ́ oníwàhálà ẹ̀dá àti ọ̀tá ọmọ aráyé tí ó jẹ́ pé nípasẹ̀ àṣẹ Olódùmarè àti Ọ̀rúnmilà nìkan ni a ṣe lè borí rẹ̀.

Akéwì kan tún sọ pé:

Bara tí ń jẹ Látọpa
Tàbìrìgbọ́n
Tàbìrì gbọ̀ǹgbọ́n abóníjà wá kùmọ̀
Èṣù Láàlú onílé oríta
Mo ṣèbà rẹ
A-dúró-ti-oníyán má sì í
A-dúró-talámọ̀là mọ́ rà
Ó dúró ti oníjà
Ó ní kólè ba à ga ruru
Onímín ń su mí
Láaróyè ń sù fun
Ẹlẹ́kuń níí sunkún
Láaróyè ń sẹ̀jẹ̀

Àyọlò òkè yìí fi hàn pé Òrìṣà alágbára ni Èṣù. Ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn rẹ̀ sì ni pé Òrìṣà tí ó lè ṣe èyí tí ó wù ú ni. Ìdí nìyí tí apohùn rẹ̀ fi sọ pé "A-dúró-ti-oníyán má sì í", "A-dúró-talámọ̀là mọ́ rà", "Ó dúró ti oníjà", "Ó ní kó lè ba à ga ruru" látí ìlà kẹfà sí ìlà kẹsàn-án túmọ̀ sí wíwá ìjà ènìyàn. Èyí ṣe déédéé pẹ̀lú èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá nípa pé bí ènìyàn bá dúró ọlọ́jà tí kò ra ọjà, tí kò sì tajà, tẹnu ọlọ́jà ni irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ fẹ́ gbọ́. Irú ìwà yìí sì lè dìjà tí yóò dá yánpọn-yánrin sílẹ̀. Agbára dàrú-dàpọ̀ yìí ni apohùn Èṣù tún ní lọ́kàn nínú ewì ìsàlẹ̀ yìí nígbà tó sọ pé:

Ẹni tÉṣù bá ń ṣe kì í mọ̀
Ó lè máa jí owó olówó
Kó jí aṣọ aláṣọ
Kó jí roko olóko
Kó sì lọ máa mú nǹkan tí kò gbìn
Èṣù ní ń ṣe onítọ̀ún

Àyọlò ewì Èṣù òkè yìí fi agbára Èṣù hàn gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà ti ó ní agbára láti mú kí ènìyàn ó ṣìṣe. Ó sì tún lè mú kí ènìyàn ó ṣi ìwà hù. Àtipé bí a bá rí ènìyàn tí ó hu ìwà àìtọ́ láwùjọ bí i; kí ó máa lọ mú ohun tí kì í ṣe tirẹ̀, tàbí kí ó ṣe ohun tí ó lè jọ bí ẹni pé wọ́n dì í ní ojú àwọn ènìyàn, ó lè jẹ́ pé Èṣù ni ó ń ṣe irú ẹni bẹ́ẹ̀. Àwọn apohùn Èṣù máa ń lọgun agbára Èṣù yìí nínú ìpohùn wọn láti fi pé àkíyèsí àwùjọ sí agbára tí Èṣù ní. Ewì ajẹméṣù gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn àwùjọ Yorùbá náà ń lọgun ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ́ gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe jẹyọ nínú ewì yìí. Gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ inú ewì Èṣù náà kò ṣe àjèjì sí àwùjọ. Èyí sì ṣe déédé pẹ̀lú èrò àwọn onímọ̀ soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ tó sọ pé, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ máa ń lapa nínú lítíréṣọ̀ irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀. Apèṣù ní:

Èṣù kò ni ohun un rà lọ́jà
Egúngún Ọbagbémilé
Ó gba tàràrà ọjà lọ
Èṣù kò tà, bẹ́ẹ̀ ni kò rà
Bẹ́ẹ̀ sì ni kò mú owó lọ́wọ́
Aápọn ni Ẹlẹgbáá wá lọ
Èṣù ní í ba ẹnikan ṣoṣo jà
Tí í fi ọwọ́ gún gbogbo ilé ní imú

Àyọlò ewì Èṣù òkè yìí tọ́ka sí pé Èṣù ní agbára láti dá aáwọ̀ sílẹ̀ láàárín ọ̀pọ̀ ènìyàn. Ó sì tún lè mú kí ènìyàn ó si ìwà hù. Nínú àyọlò òkè yìí a rí Èṣù gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà alágbára tí ó lè fi agbára rẹ̀ jẹ kí ènìyàn ó ṣe ohun tí kò ti ọkàn onítọ̀hún wá. Bí a bá wo ìlà kìn-ín-ní, ìkẹta, ìkẹrin ati ìkarùn-ún, a ó rí i pé bí ènìyàn kan bá lọ sí ọjà bí kò bá ṣe ẹni tí ó fẹ́ ra ọjà, yóò sì ṣe ẹni tí ó fẹ́ ta ọjà. Ṣùgbọ́n Èṣù tí ó lọ sí ọjà nínú ewì òkè yìí, kò lọ ra ọjà, bẹ́ẹ̀ sì ni kò lọ ta ọjà, kò sì sí ẹni tí ó lè sọ pé kín ni ó wá ṣe ní ọjà.

**Àgbálọgbábọ̀**

Ohun tí a yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí ni àfihàn agbára Èṣù nínú àṣàyàn ewì ajẹméṣù. Àbájáde iṣẹ́ yìí fi hàn pé nípasẹ̀ ìtúpalẹ̀ ewì ajẹméṣù, a rí i pé Èṣù jẹ́ Òrìṣà kan tí àbùdá agbára rẹ̀ ní ipa pàtàkì nínú ìgbé-ayé àwọn ènìyàn àwùjọ Yorùbá pàápàá nínú ètò ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ tó níiṣe pẹ̀lú àbùdá tibi-tire tí Olódùmarè dá ayé. Bákan náà, isé yìí ṣe àfihàn pé ọ̀pọ̀ ìpohùn Yorùbá tí ọ̀rọ̀ nípa Èṣù ti máa ń jẹyọ ni ó máa ń ṣe ìgbéyọsíwájú àbùdá agbára ṣebi-ṣere tí Èṣù ọ̀dàrà ni. Iṣẹ́ yìí ṣe àfikún ìmọ̀ tí ó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ lórí Èṣù pàapàa lórí àfihàn agbára rẹ̀ nínú èwì ajẹméṣù. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé, inú ẹsẹ Ifá ni ewì ajẹméṣù ṣodo sí jù. Nítorí pé ó fẹ́rẹ̀ẹ́ máà sí odù-Ifá tí kìí sọ̀rọ̀ nípa Èṣù. Nítorí ìdí èyí, ewì ajẹméṣù kò lè parun. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àyípadà ni ó ti bá a, síbẹ̀ àwọn ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀, pàápàá àwọn babaláwo kò lè fi ṣẹ́re rárá nítorí pé Èṣù ni ó máa ń gbé ẹbọ fún gbogbo àwọn Irúnmọlẹ̀ yòókù. Òun sì ni ó tún mọ ojú àwọn ajogun.

## Àkójọpọ̀ orúkọ ìwé


Abímbọ́lá, W. (1968). *Ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu Ifá*. Apá kìíní. Glasgow: Collins.

Adékúnlé, D. (2002). *Èṣù Oduism The Transcendental Orthodox Religion of Òduà Race*. Ilé-Ifẹ̀, Ọ̀ṣun State Secretariat.

Aiyejina, F., (2009). "Èṣù ẹlẹ́gbára: a source of an alternative theory of African literature and criticism". Retrieved from www.researchGate/googlesearch.com on 25th January, 2018.

Ajíbádé, G.O., (2009). *Finding female voice*: *A social-cultural appraisal of Yorùbá Nuptical Poetry*. Germany: Rudiger Koppe Verlag Koln.

Àlàbá, O., (2004.). "Àṣàrò lórí méjì nínú oríkì láaróyè (Èṣù)". Láàńgbàsà: *Journal of Department of Linguistics and Asian Studies.*

Alana, O., (2004). "Traditional religion". Nínú (Eds.) Lawal, Nike. S, Sadiku Mathew. N, and Dọ̀pámú, Adé. *Understanding Yorùbá life and culture*. Trenton, NJ: African World Press, o.i. 65-80.

Anita, P., & Paulus, S., (2016). "Saussurian binary opposition as the narrative structure of Williams' Summer and Smoke". *Journal of Department of English Letters*. Retrieved from www.e-journal.usd.ac.id/google search.com on 21th October, 2019.

Anton, G., (1981). *History of binary and other non-decimal numeration*. United states of America: Library of Congress Cataloging in Publication Data. Retrieved from www.book.google search.com on 23th October, 2019.

Asar, I., (2012). "Understanding àṣẹ and its relation to Èṣù among the Yorùbá and àṣẹ in ancient Egypt". The mocha-versity *Institution of Philosophy and Research*. Retrieved from www.asarimhotep.com/google search on April, 4th 2018).

Barber, K., (1990). "Oríkì: women and the proliferation and merging of Orisha". *Africa*: *Journal of the International African Institute*, Fol.60, o.i. 313-337.

Dọ̀pámú, A., (2000). *Èṣù the invisible foe of man. A comparative study of satan in Christianity, Islam and Yorùbá religion.* Ìjẹ̀bú-òde: Shebíotimọ Publications.

Euba, F., (1989). *Archetypes, imprecators, and victims of fate: Origins and development of satire in Black Drama*. New York: Greenwood Press. Retrieved by www.books.google search.com on 30th January, 2018.

Fálọlá, T., (2013) "Yorùbá god, power and the imaginative frontiers". Nínú Tóyìn Fálọlá (ed) *Èṣù: Yorùbá god, power, and the imaginative frontiers.* Carolina: Academic Press. Retrieved from www.books.google search.com on 25th January, 2018.

Ìdòwú, E.B., (1962). *Olódùmarè: God in Yorùbá belief*. African: Tree Press, L.I., NY.

Igboin, B.O., (2019). "Olódùmarè and Èṣù in Yorùbá religious thought". *Yorùbá Studies Review*, Fol.4, Nọmba 1, o.i. 209-232.

Ilésanmí, T.M., (1988). "Tíọ́rì àbùdá oníbejì fún àgbéyẹ̀wò lítíréṣọ̀ Ifá". Nínú YORÙBÁ: *Journal of the Yorùbá Studies Association of Nigeria*.

Lévís-Strauss, C., (1972). *Structure anthropology*. Harmondsworth: Penguin.

Kristen, H., (2005). "Theology thursdays: Transformations of Èṣù". Retrieved by www.book.google search.com on 25th January, 2018.

Ògúnbọ̀wálé, P.O. (1980). *Àwọn Irúnmọlẹ̀ Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited.

Onyibor, M.I., & Eégúnlúsì, T.R., (2019). "A critique of traditional Igbo and Yorùbá moral perspectives of evil". *CSCANADA: Canadian Social Science*. Vol 15, No. 3, o.i. 62-72. Retrieved from www.google search.com on Friday 19th, April, 2019.

Ọpẹ́ọlá, S.M., (2001). *Odù: A repository of the secret of Òrìṣà Tradition*. Ilé-Ifẹ̀: Kabbalah Centre.

Pemberton, J., (1976). "The Yorùbá trickster god". Nínú UCLA *James S. Coleman African Studies Center*. Retrieved from www.google search.com on 17th, May, 2018.

Peter, M., (1997). *Hail Orisha! A phenomenology of a West Africa Religion in the Mid-Ninetheenth Century.* New York: Brill, o.i. 43-44 Retrieved by www.google search.com on 25th January, 2018.

Sa'adu, T. (2021). "Àgbékalẹ̀ àti àkóónú ewì ajẹméṣù ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ àti Ọ̀ṣun ní Nàìjíríà (Formand content of Èṣù-related poetry in Ọ̀yọ́ and Ọ̀ṣun states of Nigeria, (Doctoral dissertation Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.)

Simpson, G.E., (1994). *Yorùbá religion and medicine in Ìbàdàn*. Ìbàdàn: University Press.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** SA'ADU, Taofiq. Àfihàn agbára èṣù nínú àsàyàn ewì ajẹméṣu. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 154-171, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Sa'adu, Taofiq (jan./jun.2025). Àfihàn agbára èṣù nínú àsàyàn ewì ajẹméṣu. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 154-171.